POLOWO ọja rẹ ninu iwe 'Irohin Yoruba' Oloyinmọmọ ti o nta ni ọja bi akara gbigbona.

Irohin Yoruba

NO. 961 WEDNESDAY JAN. 8—TUESDAY JAN. 14, 1964 KOBO META 3D

Ọrọ agba

OPẸRẸKẸTẸ ndagba, inu adamọ mbajẹ. Otitọ d'ọja o kuta, owo lowo la nrẹke; otitọ ni bori irọ nikẹhin.

ẸGBẸ ODUDUWA RANRI

OBA SIKIRU ADETỌNA

ẸGBẸ Ọmọ Oduduwa ti kọ jalẹ lati yi orukọ rẹ pada si ohunkohun nitoripe awọn enia ti o duro fun ẹgbẹ na ninu ipade awọn Ọba ati Ẹgbẹ Ọmọ Yoruba ti nwọn ṣe ni Ibadan ni ọjọ kẹta oṣu kini ọdun yi ko ni aṣẹ ẹgbẹ na lati fa orukọ rẹ fun ohun miran.

Awọn ọmọ ẹgbẹ Oduduwa bi melo kan ti nwọn lọ si ipade na jẹwọ wipe awọn lọ si ipade na lorukọ ara wọn ni.

Awọn ọmọ ẹgbẹ Oduduwa na ti o lọ si ipade na lorukọ ara wọn ni Dokita Akinọla Maja, Oloye S. A. Akinfẹnwa, Dokita Doherty, Oloye Okupẹ, Oloye S. T. Osoba, Alhaji Y. S. Ishola, Alhaji Asinnolowo, Johnson Omiṣore, Adefarakan, Oloye Adebule, Oloye Oyeṣina ati Oloye Adeyẹmọ.

Gẹgẹbi ọrọ ti awọn agbọrọsọ awọn enia wọnyi sọ fun ipade na, Dokita Akanni Doherty ati Oloye S. A. Akinfẹnwa sọ lẹkunrẹrẹ pe awọn ko ni aṣẹ rara lati tọrun ẹgbẹ Ọmọ Oduduwa bọ ọrọ yiyi orukọ ẹgbẹ na pada.

IKEDE ETAN

Ajọkọ sita ti ipade na gbe jade lẹhin ipade na kede wipe ẹgbẹ Ọmọ Oduduwa ati ẹgbẹ Ọmọ Yoruba ti dapọ di ẹgbẹ Ọmọ Ọlọfin.

Agbẹnusọ ninu awọn ọmọ Ẹgbẹ Ọmọ Oduduwa ti o lọ si ipade na sọ fun oniwe irohin wa pada pe "awa ko fara mọ ipinnu lati yi orukọ ẹgbẹ wa pada si 'Ọmọ Ọlọfin' nitoripe ẹgbẹ Ọmọ Oduduwa ko fun wa ni aṣẹ."

Ipade na bẹrẹ pẹlu ọrọ lori iṣọkan awọn ọmọ Yoruba lati ẹnu Adajọ agba Naijiria, Ọlọla Adetokunbọ Ademola. O tun sọrọ pe ete ipade na ni lati pari ẹ̀awọ yowu ti o ba wa larin ẹgbẹ Ọmọ Yoruba ati ẹgbẹ Ọmọ Oduduwa.

Kete ti Ọlọla Adetokunbọ sọrọ tan ni Oloye H. O. Davies ti iṣe ọkan ninu ẹgbẹ Ọmọ Yoruba sọ pe afi ti nwọn ba yi orukọ ẹgbẹ mejeji na pada, ti nwọn si jijọ jẹ orukọ kan na.

ẸGBẸ OSELU

Ọba Alaiyeluwa Ọlọla Adesoji Aderẹmi, Oni ti Ifẹ ti o jẹ alaga ipade na kilọ pe ti nwọn ba yi orukọ ẹgbẹ ti nwọn fi da Oduduwa ti iṣe baba Yoruba lọla pada yio ṣe jamba fun iṣọkan

(Wo oju ewe kejọ)

OBA ADESOJI ADEREMI
On ni alaga ipade na

'YORUBA PARAPỌ' KAGBAKO

GBANGBA dẹkun kedere bẹwo Ọgbẹni Bọla Ige Akọwe ikede ẹgbẹ Afẹnifẹre bọ aṣọ loju egungun ni Ibadan lọjọ Ọjọbọ ti iṣe ọjọ keji oṣu kini ọdun yi nigbati o sọ faiye gbo pe, "ero lati fa awon enia pe lati inu ẹgbẹ Alakuko, Afẹnifẹre ati Ọlomolangidi fun idibo si Ile Igbimọ Asofin Iwọ Oran ti awọn ti nfi igba pipẹ tẹnu mọ ti nlo lowolowo bayi.

O la ọrọ na dẹlẹ kedere pe, awọn ẹgbẹ ọmọ Yoruba yio si ṣe ipade kan ni gbọngan Western Hall ni ọjọ kẹta oṣu kini ọdun yi lori ati ona ero yi ṣe.

AWỌN ADAJỌ

O si ṣe alaye pe awọn ti nwọn pe si ibi ipade na ni awọn Ọba Yoruba patakipataki, awọn Ijoye, ati gbogbo awọn Alakoso ọmọ Yoruba ninu Ijọba Apapọ ati ti Ipinlẹ pẹlu awọn asaju oselu ati Adajọ agba Ijọba Apapọ, Ọlọla Adetokunbọ Ademọla.

Ọgbẹni Ige si tun ṣe alaye siwaju pe, "gbogbo Adajọ ile ẹjọ giga ti o jẹ ọmọ Yoruba ni Eko ati ni Iwọ Oran ni awọn ti pe si ipade na".

O si fi han pe, "ọtẹ nla ati dojuti ifẹ ati otitọ awọn ọmọ Naijiria lapapọ ati ti awọn ọmọ Iwọ Oran ni pato dẹlẹ ni eyi." O fi kun ọrọ pe, "awọn ti o wa ni idi̇ọte na ni awọn Ẹ̀ojiṣẹ ijọba apapọ Naijiria ṣe kilọkilọ yi fun awọn Adajọ ile ẹjọ giga pe:- "Ki nwọn maṣe sọ ara wọn di irin iṣe yẹyẹ oṣelu.

"Ti ẹ ba wa, gbogbo awọn enia oriledede yi ni yio gbaraja

Wo oju ewe karun

ỌGBẸNI BỌLA IGE

dẹru adamkan pase, ati atẹnilorika, ti nwọn si ngunni lojojumọ lati pa ẹgbẹ Afẹnifẹre ati awọn ẹgbẹ oluṣe ijọba iluri miran kakiri orilẹede yi run patapata"

Ọgbẹni Ige si sọ ninu iwe rẹ pe, "Ẹgbẹ Afẹnifẹre Na-

Ijọba Egbẹ Ọlọpe yio da Raji pada

Adele asiwaju egbe Afenifere Naijiria, Alhaji Ọlọla D. S. Adegbenro so fun ipade awon oniwe irohin ni Ibadan ni ojo Isegun ti ise ojo kokanlelogbon osu kejila odun ti okoja pe Ijoba titun egbe Afenifere yio da Oba Raji Adebowale Aseyin ti Iseyin ti ijoba ajumose egbe Alakuko ati UPP ro loye, ti nwon si wa kuro lori Ite re ni ojo Aje ti ise ogbonjo osu kejila odun 1963 pada si ori oye re.

Nigbati o bawonoiroh in sọrọ lori yiyọ Ọba na kuro lori oye rẹ, Alhaji Adegbenro sọ pe ibanujẹ nlanla ni yiyọ kuro na jẹ nitoripe Ijọba yan Ọba Adebowale ni ibamu pẹlu akọsilẹ ofin eto ifinijoye.

Alhaji Adegbenro fihan kedere pe lati igbati Ijọba ajumose pọ ẹgbẹ Alakuko ati ti Olomolangidi ti gba agbara lati oṣu kejila odun 1962 koiti si irohin tabi ẹsun rughodiyan ati irukerudo. O wa lere bayi "Tani ẹni na ti a se idilọwọ fun tabi kini ifaiyabalẹ tabi Ijọba rere ti a ti bi ṣubu?

Alhaji Adegbenro, ti o wa nibi ipade onirohin pẹlu Oloye J. A. O. Odebiyi ẹniti iṣe alakoso eto inawo tẹlẹ ati Ọgbẹni Agunbiade Bamiṣile, alabojuto ẹgbẹ Afenifere tun mọ pe yiyọ Ọba Adebowale lati ọwọ Ijọba Akintola ko sai jẹ mọ ọrọ oṣelu.

Gẹgẹbi ọrọ adele ẹgbẹ Afenifere "Bi Ijọba ba ofe si alafia ifaiyabalẹ ati Ijọba rere ọba ti a rọ loye ni ẹniti o yẹ ki Ijọba dabobo gidi tun pẹlu idi pataki marun:

* Oloye S. L. Akintola, Ologbe Oloye J. A. Ajao ati Oloye A. O. Adeyi e ili iṣe alakoso eto iṣẹ ati irinna ninu Ijọba Oloye Akintola ni o fa Ọba Raji Adebowale ka lẹ.

*Iwe iranti akọsilẹ gbigba a ni oba wa lori ibamu, ati pe opolopo awon orukọ Afọbajẹ ni o pe nibẹ. Bashoran ti Iseyin ni o se olori afọbajẹ nigbana.

IMỌ ALAFIN

*Gbogbo awọn afọbajẹ na ni o fi tifetife gba Ọba Raji Adebowale gẹgẹ bi Aseyin ti Iseyin ati pe nwọn si gba mọran lọdọ Alafin Ọyọ gẹgẹ bi ibamu pẹlu eto di se iṣeri, ẹniti oni fun awon Afọbajẹ na ni imọran lojọ na ni Ọlọla Bello Gbadegesin Alafin Ọyọ kia to fi ọwọ si lati owo awon afọbaje ilu Iseyin ki awon Igbimọ Ipinlẹ Iwọ Orun to fọwọ si yiyan Ọba Raji Adebowale gẹgẹ bi Aseyin ti Iseyin.

"Lẹhin ti o di ikolorun pẹlu Ẹ̀gbọnle awọn Afọbaje ilu Iseyin ati imọ Alafin tikara rẹ, ni Igbimọ Ijọba to fi ọwọ si oye Ọba Adebowale gẹgẹbi Aseyin ti Iseyin.

"Lẹhin igbati a ti yan Ọba Raji Adebọwale gẹgẹbi Aseyin, igba maji ni alatako rẹ gbe lọ sile ẹjọ giga lori oye yi, gbogbo ẹjọ na ni Ọba Adebowale jẹrẹ rẹ patapata. Ileẹjọ si pinnu pe ko si iruju ninu yiyan Ọba Adebowale, o si jẹ ibamu pẹlu akọsilẹ ofin eto ifinijoye.

Alhaji Adegbenro wa sọ bayi pe onisowo kan ko ni fẹ wa si orilẹede Naijiria nitoripe nwọn yio ma bẹru pe awọn oṣelu orilẹ-ede yi ko ni igbekele nkan alajọ ododo.

Alhaji Adegbenro sọ ewa ti a fi kan pe awọn olukọni ile ẹkọ giga Unifasiti Ifẹ wa ninu awọn ti ẹgbẹ Afenifere nfun ni owo-oṣu.

O fi kun ọrọ re "Awọn olukọni ile-eko giga Unifasiti ye fun ọpẹ ati ọyẹ gbogbo wa ati pe bi Oloye Akintola ati awọn alakoso rẹ ko ba mọ iyi tabi ọpẹ fun awọn enia wọnyi, o yẹ ki on ati alogbe rẹ kuku yẹ awọn olukọni na silẹ lasan."

B&Y POOLS LIMITED

CERTIFIED DIVIDENDS FOR JANUARY 4, 1964: 12 DRAWS ON COUPON

8 Treble Chance Draws

14 DRAWS ON COUPON
Possible Points 24
1st Dividend 24 Points
£217 : 15 : 0d for 1d
2nd Dividend 23 Points
£8 : 0 : 0d for 1d
3rd Dividend 22 1/2 Points
£3 : 12 : 0d for 1d
4th Dividend 22 Points
£0 : 10 : 0d for 1d
(4 Dividends only See Rule 10F)

8 Treble Chance Aways

12 Aways on coupon
Possible Points 24
No Client with 24 Points
1st. Dividend 23 Points
£85 : 7 : 0d for 1d
2nd Dividend 22 1/2 Points
£31 : 0 : 0d for 1d
3rd Dividend 22 Points
£2 : 4 : 0d for 1d
4th Dividend 21 1/2 Points
£0 : 4 : 0d for 1d
(4 Dividends only See Rule 10F)

7 Treble Chance Draws

Possible Points 21
1st Dividend 21 Points
£150 : 10 : 0d for 1d
2nd Dividend 20 Points
£4 : 5 : 0d for 1d
3rd Dividend 19 1/2 Points
£0 : 19 : 0d for 1d
(3 Dividends only See Rule 10F)

3 Draws Pool
37/- for 1/-

4 Aways Pool
110/- for 1/-

9 Results Pool
(Paid on 8 correct only)
127/- for 1/-

All dividends are declared to Units of 1/- except the 8 and 7 Match Treble Chance Pools and the 8 Match Treble Chance Aways which are declared to Units of 1d and are subject to scrutiny.

B. & Y. POOLS LIMITED
P. M. Bag 5193, Ibadan.

Alapara Ibadan

ỌRỌ OLOTU

KINI ẸṢẸ KABIYESI ?

NI oju kini iwe IROHIN YORUBA ti ọṣẹ ti o koja, a tẹ irohin Oba Raji Adebọwale ti Ijeba Ajumọṣe Alakuko ati Omolangidi yọ loye, ti nwọn si tun wa lọ si Ebute Irele ni ọkun Ohitipupa jade. Iwe aṣẹ ijoba ti nwọn fi kede iwa aburu yi ko sọ ohunkohun ti o fa lile oba na kuro lori itẹ.

YIYỌ oba na kuro lori oye ru IROHIN YORUBA lọju gidigidi. O yẹ fun iyẹwo awọn oba, ijoye ati mẹkunnu agbegbe Oyọ ni pataki julọ ati Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria ni apapọ nitoripe ohun ti o ba ba eju gbodọ ba imu. Awọn onilaakaye enia gbodọ gba iwe aburu yi yẹwo.

OBA Raji Adebọwale ko fi eru gba ibukun bi awọn enia kan ni Ipinlẹ Iwọ Orun ṣe fi eru gba ibukun ni ọdun ti o koja. Bi Oba Raji ṣe gun ori oye ko ṣe ajeji rara si eto isẹmbaiye Yoruba ati ilana ofin.

BOGBO awọn Afọbajẹ ilu Iṣeyin ni o yan oba na. Alafin ti Oyọ, Oba Bello Gbadegẹṣin fi ọwọ si ipinnu awọn Afọbajẹ na gegebi ilana aṣa agbegbe Oyọ. Ijoba Ipinlẹ Iwọ Orun nigbana labẹ Olotu Ijoba Oloye Samuel Ladoke Akintọla ń ọwọ si yiyan Oba Adebọwale gegebi Aṣeyin ti Iṣeyin. Igba meji tọtọ ti idile oye kan ni Iṣeyin gbe ẹjọ oye na lọ si ile ẹjọ giga Ipinlẹ Iwọ Orun ni ile ẹjọ da Oba Raji Adebọwale lare.

AWỌN Afọbajẹ ilu Iṣeyin eyiti olori re ise Bashọrun ti o yan oba na ni ọdun 1960 ko iti ku, awọn wa laiye. Alafin ti Oyọ, Oba Bello Gbadegẹṣin ti o ń ọwọ si yiyan oba na gegẹ bi Aṣeyin ti Iṣeyin ti o ba ofin mu ko iti ku, o wa lori itẹ re. Peki ni o ṣe pe Olotu Ijoba Igbana, Oloye Samuel Ladoke Akintọla ti o fi ọwọ si yiyan oba na tun ni Olotu Ijoba ti o yọ oba kanna ni oye laiṣẹ, laida ati laitọwọbọ. Ile ẹjọ giga ti o da oba na lare ni igbameji ko iti yi ipinnu re pada.

KI wa ni ṣẹṣẹ ẹni ami ororo ilu Iṣeyin yi? Rogbodiyan ko bẹ silẹ ni ilu na. Alafia ati ifaiyabale ko borẹjọ. Awọn enia ilu Iṣeyin ko sọ wipe oba awọn sunwọn. Ipinnu awọn Afọbajẹ ko yipada.

OHUN ti o ṣẹlẹ ni Iṣeyin bayi nipe Ijoba Ajumọṣe Alakuko Fani-Kayọde ati Omolangidi Akintọla yi ipinnu awọn Afọbajẹ. Alafin ti Oyọ, ite ẹjọ giga, Ijoba Akintọla ti ọdun 1960 ati awọn enia ilu Iṣeyin ti awọn oba awọn wọn laisi ija ni ọdun 1960 pada laibere lọwọ won. Tabi o ko lati dale ni? Ilẹ ni o ma npa ẹniti o ba dale!

AWỌN enia ipinlẹ yi—oba, ijoye, mẹkunnu ko gbodọ fi ọwọ ọrun rigbati awọn ẹhanna enia kan ba nhu iwa ipa. Ẹ ko le gba lati sọ pe ogede npọn nigbati o nra, ti o si nrun pelu.Iwa itẹniloriba lagbara ko le jẹ iwọnumọ rara fun awọn alọnilọwọgba. Kaka ki o ran fun iya ajẹ ni ọrọ na je, o ńfi ghoghọ ọmọ re bi obinrin; ẹiyẹ wa nyi lu ẹiyẹ. Iparun ni kẹhin aṣiṣe kan de aṣiṣe keji.

OJOJUMỌ ni Ijoba Ajumọṣe Alakuko ati Omolangidi ma nkighe wipe awọn bọwọ fun awọn oba ati ijoye Ipinlẹ Iwọ Orun, ati wipe ipo 'baba' ni awọn ń awọn oba si. Bi bẹẹni, bi bẹẹko Oba Raji Adebọwale nu-un, Oba Sammy Adetayọ ti Ijebu Igbo nu-un; Oba Samuel Akinsanya, Odẹmọ Ishara nu-un ati awọn ijoye miran ati bẹẹbẹ lọ. Awọn ọmọ Yoruba ko gai mọ wipe irọ ni lati pe ohun dudu ni funfun.

ỌMỌ ti o ba ngba baba re leli ko yai ti kolu agba. Omọ ti o ba ngba onije lẹau kaba re ti o si nkigbe kiri pe on feran baba ko yai ni ṣe alabapade iparun. Ojọ ọmọde ti o ba ntapa si awọn agba ko ni gun gẹgẹ bi Bibeli Mimọ Oluwa ti wi.

IKADO iba ṣe bi ẹlẹdẹ a ba ilu je, ẹgbẹ Alakuko ati Omolangidi iba ti wa ni ipo ọla lati ọdun 1952 wa, ayọ opolopọ oba, ijoye ati mẹkunnu iba ti di ikanuje. Gbogbo awọn ọtọkulu ko le ri gbọ abamọ ti yio bẹhin iwa aburu yi ṣe.

BI awọn ẹhanna ti ntan awọn enia je ko ba ni le tun ipo won ṣe, ko ha ni sun fun won lati ń won silẹ bi nwọn ṣe ba won? Ti Oba Raji Adebọwale ni a ri loni, ti gbe wo ni o mbẹ lọna?

ALAPARA: Ẹ ku owuro o, Olotu. Se daada lẹ ji loni o?

Olotu: Alafia ni mo ji loni o, mo dupẹ lọwọ Olodumare, Alapara oju re maa ndan gbinrin?

Alapara: Kini ẹ ri ki ẹ to wi bẹ: Nje ẹfẹ kọ ri ẹ nfi mi ṣe bayi?

Olotu: Efe kẹ? Mo ri ngto wi, Gbogbo tolotolo ati elẹdẹ ti ẹ pa fun odun Keresimesi ati odun nla, ọṣe ko ni ẹ da a ra. Mo tilẹ reti itan togbo ti o ba wa si ọdọ mi ni mo fẹ maa nibere, ṣugbọn ti a ba ti da ọrọ silẹ, titi iwọ yio fi lọ, nki ranti lati bere re ni o. Nibo ni owa nisisiyi?

Alapara: Ogbẹni Alapinni ma ti dekun arinlẹ.

Olotu: Kini o fa ti o fi d'odun arinlẹ?

Alapara: Enia abirun ni o faa.

Olotu: Bawo ni o ṣe fa a?

Alapara: Ọrọ imulẹ kan fun ire ara wọn ni

ALAPARA IBADAN

lotolo ati elẹdẹ lori ireṣi lati ọdọ re Alapara, pobọ ni gbogbo re jasi.

Alapara: Olotu, "onikun lo mọ ika," igba lọ bi orere, igba tio ba si de ni anlo. Edumare ko mu igba rere wa. Mo dupẹ lọwọ Oba Oke ti omu ni r'odun kekere ati nla. Emi nfẹ sugbon o ṣe ailera fun ara" Osin ti ko ṣin loni, le sin lọla; toto ọṣe bi owe o. Boya l'odun to mbo lagbara Odua itan ogboro malu ni ngo gbe wa fun nyin.

Olotu: "Obun ti o ba oju, ni o ba imu" toto o ṣebi owe o. Ibiti o ko ti i ṣọrọ de mo ti mọọ. Oluwa a gbe aseko rere de hawa, ka ṣa dupẹ emi to s'odun. A ṣeyi ṣọpọ odun o.

Alapara: Amin egbẹrun amin ko to!

AIYE D'EKE BE SORO E W'EHIN WO.

Alapara: Ẹ ko tilẹ ri Ogbẹni Alapinni, ẹ o si bere re Olotu?

Olotu: Ha! okunrin korọbo bi oka, lo daruko ni. Nigbagbonwon jọ pawọpo ṣe, ki ọkan ninu wọn to gbẹhin re awon yoku re lẹhin ighati ọrọ di panpayikita.

Olotu: Omode ki i mọ onije je ni, ki o ma ra lọwọ. Ogbẹni Alapinni.

Alapara: Ko ma pe ni nu gbogbo ẹda ti Oluwa da, omọ enia ni o burujulo?

Alapara: Sebi igbe omo enia ni ẹiyẹ Osin nke titi di oni oloni pe enia too-to-o fun —u-un".

Olotu: Ogbon kan tun ni Alapinni tun ko kun ogbọn ni igbesi aiye re yen, abajọ ti nko fi ri i, ti o ba fii, ṣọ fun pe mo fẹ rii, ki a bale fi oro jomi toro oro lipa AIYE AKAMARA.

Alapara Ohun ti o mu mi so eleyi fun yin nipe ki awọn onkawe mi le fi oro ti Alapinni kogbon pe enia soro finu han

Osotu: Alapara, oko gbo orin ti nwon ma a nko lehin egun kan l'Offa lasiko odun won?

Alapara: Bawo ni nwon ti nko Olotu?

Olotu: Nwon nko bayi pe:-

Aiye d'eke
Bo soro
O wẹhin wo
Aiye d'eke
O wẹni rere
Ba so

Alapara: Ododo oro ni o akiwa ko gba wa lowo ajinnileṣe omo araiye, ngo jiṣẹ yin fun Alapinni yio wa ri yin lose to mbo o.

IGBE AWO! AWO!! AWO!!! GBOJIKAN NINU ODUN KERESIMESI ATI ODUN NLA L'EKO

Alapara: Gauntan yan l'Eko lojo aisun odun nla.

Olotu: Kini o tun de o, tabi Eko lo ti ṣe odun mejeji na?

Alapara: Fedira layọ. Bi nwọn de mi mọlẹ ni ilu kan pe ki ng ma de Eko s'odun ngo ja okun l'ọjọ na. Eko ni mo wa.

Olotu: Nko yọ tẹẹrẹ ni toripe iṣẹ ko je. Se iwọ paapa mọ pe mọ pe awa ni yio tẹ lrohin Keresimesi ati odun nla jade?

Alapara: Mo ti mọ bẹẹ.

Olotu: Ki oto bẹrẹsi so t'Eko, jeki nfi ohun tio ṣẹlẹ ni Ibadan lojo aisun odun kin ọrọ tirẹ lẹhin Igbe Awo! Awe!! ni awọn alaisun nke kakiri Ibadan. Laiseaniani eti Awo yio maa ja l'ọgba ẹwọn lọhun.

Alapara: Kekere tilẹ ni yen Olotu, awọn ọmọ onigbagbọ ya ere meji laseko odun titun nwọn sọ orukọ ekini ni AKATANLA JAGUNLABI, nwọn sọ ekeji ni OLOYE OBAFEMI AWOLOWỌ.

Olotu: Agbọ ti ere Oloye Awolowọ, ẹwo ni ti Akatanla?

Alapara: Ademuyiwa npalẹ ogun mọ ni ọrọ na o. Orisa oke ma jeki o t'enu mi bọ. Iwọ ko mọ Akatanla? Ko s'eniti ko mọ ọ bi o o ko ba mọ ọ.

Olotu: O ti ye mi. Se baba ajinnileṣe yen ni?

Alapara: O ku tọ o, Olotu on gan ni o

Olotu: Kini ṣẹlẹ si awọn ere nejeji na?

Alapara: Ki awọn onigareta to bẹ sita fun ere ṣiṣe ni nwọn ti sa ere Akatanla sita ti orun bẹrẹsi pa a ni ipakupa.

Olotu: Kini fa ere Akatanla ti nwọn fi saa si orun?

Alapara: Ohun ti nwọn fi ṣe bẹẹ ni pe at'aiye ni yio ti maa je iya re lọ s'orun.

Olotu: O tilẹ ti bẹrẹ. On paapa ti nke LAILA- kẹlẹkẹlẹ nisisiyi. Oju aiye lo ku ti o nṣe nisisiyi, ọrọ ti di iso inu ẹku

(Wo oju ewe keje)

FOPINSI AWON OTUTU ATI IBA
kiwon to ba alafia re je

Majeki awon otutu ti onsa ere kiri, awon iba ti omi nkolu enia lairotele, ati lainidi tabi iko buruku gba alafia koro inu igbadun aiye re. Nigbakigba ti ohu tiri ami awon nkan wonyi — fi Mentholatum dije bo iho imu re, ki otun fi pa iwaju re, ati aiya re daradara. Wari bi Mentholatum se nsare gbogun ti orun. Isira ti pare ki ole ro daju daju wipe Mentholatum nse ore fun e. Aghayasu, aghayasu Mentholatum.

ATURA—TAWOSE—IWOSAN

Jeki Mentholatum ma wa ninu file; re ni gbogbo-igba, - ra ide, tabi agole kan loni

BERE FUN OJULOWO MEN-THO LA-TUM

MENTHOLATUM

OGUN IPARA TI ODARAJULO

Awon ti onse ni Mentholatum Company Ltd. (Est. 1889), Slough England.

Ẹgbẹ Ọdọ gbe Awo ga ni Idanre

LẸNU Iọlọ yi ni awọn ọmọ ẹgbẹ ọdọ Afenifere ti Idanre ni agbegbe Ondo s: ipade ajọdun ẹgbẹ na ni Idanre.

Awọn ọmọ ẹgbẹ na so kedere nibi ipade na ti Ogbẹni S.A. Orẹsun je alaga re ti nwọn si se ni gbongan Orosundarinre pe awọn ni igbẹkẹle kikun r'su Oloye Obafẹmi Awolowo babasalẹ egbẹ Afẹ ifere.

Bakanna ni awọn ọmọ ẹgbẹ na tun kesi Asaju ẹgbẹ na ni Ile Igbimọ Asofin Ijoba Iwọ Orun, Oloye Alhaji D.S. Adegbenro pe ki o ma ja lọ laiboju wo ẹhin fun ilọsiwaju ati ifura awon enia Ipinlẹ Iwo Orun ati Nigeria ni apapọ.

Ni ipari awọn ọmọ ẹgbẹ na yan awọn Oloye ẹgbẹ fun ọdun titun. Awọn oloye na ni :- Ogbẹni J.A. Akinwalire, alaga; Ogbẹni H. Adejayan, igbakeji alaga; Ogbẹn S.A. Orosun akọwe eto egbe na; Ogbẹni R. Ogunlẹkẹ akaro egbẹ Ogbẹni J. Ale akọwe ẹgbẹ, ati Ogbẹni A. Adekoye igbakeji akọwe. Ni ipari awọn omo egbẹ na fi ipade mran si ọjọ kokanla osu kini ọdun yi.

'Riba' gba iṣẹ lọwọ ọlọpa mẹsan

AWỌN ọlọpa mẹsan ti iṣẹ nwọn je mọ iṣẹ ọkọ ilẹ ni nwọn ti da duro l nu iṣẹ lati ọwọ Ogbẹni D. D. Willis ti iṣẹ olusakoso ọlọpa agbegbe Platu ni ọjọ Eti ti iṣẹ ọjọ ketodinlọgbọn osu kejila o tun ti o koja lori ẹsun ijẹkuje ti a fi kan won.

Ikede lati ile iṣẹ oga olopa so pe: nwon ti ba owo ti o joju lara awon olopa na nigbati nwon nse igbogunti iwa ije uje ni opopo ona Zaria si Jos.

Omo yinbon p'aya pa baba

Akẹkọ kan, ti se ọmọ ọdun mejidilogun ni a gbọ pe o pa iya re lẹhin ti o ti kev. iy re pe ki o ma bọ lori ibusun, ki o si di oju re.

Iyalẹnu bẹ silẹ ni asiko ti baba re nṣe agbar lati g a iya re silẹ lọwọ re. ni o ba yin ibọn f n baba na pẹlu, o si tun pa iya re bakanna.

A gbọ wipe awọn ọlọpa ti mu ọmọku rin na ni ilu alufoma, o si jẹwọ lẹhin opolopọ iwadi.

OLOYE OBAFEMI AWOLOWO

Majẹkodunmi gba iti ju ni Remọ

AWỌN omo ẹgbẹ Itesiwaju ọdọ Rẹmọ (Remọ Youth Front) ti kesi gbogbo Oba, Ijoye, awon alakoso Ijoba Ibile ati gbogbo omo Remọ nile ati ni idale pe ki nwon ti odi si Egbe omo Yoruba eyiti Dokita M.A. Majekodunmi je oludasile ati olori re.

Dokita Majekodunmi

Awon omo egbẹ na so ninu iwe kan ti nwon fi sowo si ile irohin wa ni aipẹ yi pe ohun ti o han si gbogbo enia ti nwon si mo dunju ni pe, awon Yoruba ti ni egbẹ ibile kan lapapo eyi si ni Egbẹ omo Oduduwa. Eyi si to lati fihan pe egbẹ asẹsẹdaiye ti Dokita Majekodunmi je omo bibi igbeyawo asa-Iimosi egbẹ olomolangidi ati olomi U.P.P / NPC. Eyi si ni lati fihan bakanna pe omo egbẹ olomi ni Dokita Majekodunmi ise.

Awọn Omọ egbẹ odo Itesiwaju Remọ titori eyi pe gbogbo Oba ti o wa ni ẹkun Remọ lati so gbangba fun aiye gbọ ohun ti oju won da nipa irohin ti o jade pe Dokita Majekodunmi se ipade idasile Egbẹ omo Yoruba ni ile Alaperu ti Iperu.

Ni ipari awon omo egbẹ na kesi gbogbo awọn olufe otito ati ifura jakejado Iwo Orun lati jawo ninu egbẹ akotileta yi.

Akinfosile koja aye re

OLỌLA Abubakar Balẹwa, Olotu Ijoba Apapọ Naijiria ti so gedegbe fun aiye gbọ pe ko si ọkan ninu awọn alakoso on ti aye gba tọbẹ lati bẹ ibẹkubẹ laiye re lai si owọ on O so gedegbe pe kii se eto Alakoso on kankan lati so boya nwọn ma se pasiparọ oye Alakoso Ijoba Apapọ kan tabi nwọn ko ni see.

Ololа Abubakar so eyi ni idiko ofurufu ni Ikeja ni kete ti o pada ti Ariwa nibiti o ti lọ lo aye isimi kekere de.

O fesi si ibere kan lati enu awọn onirohin pe, "Olotu ni o ni eto lati so boya pasiparọ aye le wa tabi ko ni si ninu awọn akoso ijoba re"

Ọrọ ti Ogbẹni Olu Akinfosile Alakoso eto Waya so lori pasiparọ yi, nigbati o lọ si Ile Ifẹwe ranse titun kan ni Ipinlẹ Ila Orun ti o si jade ninu iwe irohin kan ni Eko je ohun ti o ti mu ọkan awọn enia sọna fun igbati a tunṣe na yio waiye.

KO NI ETO

Irohin na te sita pe Ogbẹni Olu Akinfosile ahuu si ibere awọn ara Aguata ni Ekun Awka pe "Adura on ni ki eniti o ba gba ipo on le ri si ibere won gbogbo".

Ololа Abubakar tako ọrọ na gbangba nigbati o wi fun onirohin kan pe, "Tani o bere alaye re. "Enu tani o ti jade ?

Onirohin na si fesi pe, "ọkan ninu awọn Alakoso re ni o so."

Ololа Abubakar tun se ifesi si ibere kan lori ikania ti o koja pe, bi isoro kankan ba wa nipa ikania na, a je pe larin awọn igbimọ akanian ni.

Alakukọ bere iwadi si igbimọ Alakukọ

Igbimọ Majekobaje egbẹ Alakuko agbegbe Ilesha, ti o se ayewo rogbodiyan ti o wa larin egbe na ti da Ogbẹni B. Olowofoyeku alakoso eto, Idajọ Ijoba Iwọ Orun lare lori ẹsun ti awon kan ninu omo egbẹ na fi kan pe o nfe da oju egbe na dele ni agbegbe Ilesha.

Awon Igbimọ na fi enu sokan pe awon ni igbekele ki kun ninu Alakose na, nwon si se ipinnu pe ki nwon se ayewo iṣẹ egbe Alakukọ agbegbe Ilesha lati ọjọ kokandinlogbọn osu keje odun yi.

Awon Igbimo na tun se ipinnu pe, ki nwọn se ayewo Ijoba Ibile Ilesha eyi ti awon o.no egbe Alakuko je Igbimọ Afunsọ re nisisiyi.

Remọ

ruba eyiti Dokita M A. Majekodunmi je oludasile ati olori re.

Awon omo egbẹ na so ninu iwe kan ti nwon fi sowo si ile irohin wa ni aipẹ yi pe ohun ti o han si gbogbo enia ti nwon si mo dunju ni pe, awon Yoruba ti ni egbẹ ibile kan lapapo eyi si ni Egbẹ omo Oduduwa. Eyi si to lati fihan pe egbẹ asẹsẹdaiye ti Dokita Majekodunmi je omo bibi igbeyawo asa-Iimosi egbẹ olomolangidi ati olomi U.P.P / NPC. Eyi si ni lati fihan bakanna pe omo egbẹ olomi ni Dokita Majekodunmi ise.

Awọn Omọ egbẹ odo Itesiwaju Remọ titori eyi pe gbogbo Oba ti o wa ni ẹkun Remọ lati so gbangba fun aiye gbọ ohun ti oju won da nipa irohin ti o jade pe Dokita Majekodunmi se ipade idasile Egbẹ omo Yoruba ni ile Alaperu ti Iperu.

Ni ipari awon omo egbẹ na kesi gbogbo awọn olufe otito ati ifura jakejado Iwo Orun lati jawo ninu egbẹ akotileta yi.

ENU ko gba irohin, gbẹgedẹ gbina ni ọjọ Abameta ti iṣe ọjọ kẹrinla osu kejila odun ti o koja ni Mushin ni-biti awọn egbẹ Afenifere Odọ ti ọṣe ipade won. Ogunlogo awon enia ni o wa sibe papa opoplopọ ninu awon enia yi je awọn ti ki ise omọ egbẹ Afenifere tele sugbon ti nwọn pinnu ni ọkan won lati duro sinsin lẹhin asiwaju egbẹ Afenifere, Oloye Obafẹmi Awolowọ ati igbakeji re, Alhaji D. S. Adegbenro, lẹhin ti nwọn ti mọ riri iṣẹ ti nwọn se fun awọn enia ni ipinlẹ Iwọ—Orun Naijiria.

Ni ile alaga egbẹ Odọ Afenifere, Ọbeni Ola Abayọmi ni nwọn pe ipade na si, nibe ni gbogbo nwọn si ti se ipinnu bayi pe —

"Awọn ti duro ti Oloye Obafẹmi Awolọwọ ati igbakeji re Alhaji Dauda Shoroye Adegbenro, nwọn tun so pinnu ọrọ nwọn pe idanwo ti o ba egbẹ Olọpẹ. eyiti egbe na si ti ba Olorun duro, da-judaju egbe Afenifere yio segun lojo iwaju pẹlu aṣẹ Oluwa."

Ninu ipinnu keji, egbẹ Afenifere Odọ re awọn ọmọ egbẹ na pe ki nwọn o maṣe titori owo gbe ilu wọn ta fun awọn Gambari, ki a ma si titori owo gbe ogo le wa sonu nitoripe opolopọ awon'enia wa ni orile-ede Naijiria papa ni Ipinlẹ Iwọ-Orun Naijiria ni nwon titori owo gbe ilu baba won ta, eyiti Eleda papa lodi si.

Ipinnu kẹta, awọn egbẹ na tun fẹnu ko le lori iṣipe nigbagbogbo ni awọn yio ma ṣe atako si Egbẹ Ọmọ Yoruba nitoripe awọn ko nife si egbẹ akotileta bẹẹ rara ati pe dida egbẹ na silẹ je ọna lati gbe ogo Ipinlẹ Iwo-Orun sonu, A fi bẹẹgbẹ na ba gba lati se irounpiwada ki gbogbo won si gbarajọ lati tẹle Egbẹ Ọmọ Odudua, eyiti iṣe egbẹ omo Ibile Yor ba.

Akowe Igbokegbodo egbẹ Odọ Afenifere ni Ilu Shomolu, Ogbẹni F.A. Ola Adanijo tun so pe iru ogunlogo enia biti ojo na ko ti se ipade ri nitorina eleyi fihan pe iṣẹgun nbẹ fun egbẹ Afenifere lọjọ iwaju.

Ayaba Ji Pẹpẹiyẹ

AYABA kan ni Ijẹbu jewọ niwaju ile-ejọ giga kan ni Ijẹbu-Ode lori ẹsun pe o ji pẹpẹiyẹ gbe, adajọ si fi si ewon osu kan pẹlu iṣẹ asekara tabi ki o san ẹgbẹrun marun gẹgẹbi owo itanran

Iyafin Florence Adedoyin, eniti iṣe eni ọdun marun elogoji, Iyawo Oba Jimọ Adedoyin, ti iṣe Olowu keji ti ilu Okun-Owa ni itosi Ijebu-Ode.

Awon Olopa ti ẹsun kan Florence Adedoyin pe ni ọjọ kini osu kẹrin ọdun yi, ni ọdaran na gbe pẹpẹiyẹ eyiti iye re to sile meje – abọ (7/6) eyiti iṣe ti oluko kan, Ogbẹni Amos Adelaja ni opopo Itun-Oja ni ilu Okun-Owa, o si ta a fun Sifau Kadiri ẹniti a mu mọ obinrin na ti ngbe ni Ijesha-Ijebu ni nkan bi ibuso merin si wọn.

Florence ranti pe on ko jẹbi, o si ti pẹjọ ko temi lorun, wọn si gba iduro re, sugbon a da Sifau Kadiri silẹ pe ki o ma lọ ni alafia eleyi ni eniti Florence ta pepẹiyẹ na fun

Adajọ Ogbẹni M.O. Obisanya gba imoran agbejoro Ogbẹni Oluwole Omotọmọ, pe ko ni ejọ lati je, o ni o ra pẹpẹiyẹ na ni ọja pẹlu iye ti o kunju.

Abami ọmọ sọ ara rẹ l'orukọ

NIGBAKAN ri, ni ilu nla kan ti anpe ni Ojumiri, obinrin kan wa tiobi ọmọ kunrin kan ti o lẹwa gidigidi, ṣugbọn bibi ti nwon bi i silẹ oru lo bere si iso, oni "A! bayi ni aiye ri; Kini mo ba wa si, nko mo pe bayi ni aiye buru to, mo sebi aiye yio ma dan bi orun"

A! ẹ wo koto, ẹ wo gegele, ẹ wo ẹmi ẹran ni igboro ilu. Ẹ wo idọti larin ọdẹ, mo gbe na wayi, nko mo ni pe pada lọ si ọrun ni temi ojare.

Ẹyin akikanju ọkunrin inu aiye ọmọ ti nwọn bi lojọ ni onṣe bayi sọrọ o. Bi o ti wi bayi tan na ni o dide ni ilẹ ibiti wọn bi si.

Ko jẹ ki ẹnikan tabi ẹnikẹni gbe on, o bọ si iyara iya rẹ o mu kaninkanin o mu ọṣẹ o wẹ ara rẹ dada, o fi aṣọ daradara bora o le gongo.

Ko ipẹ ti o joko na nigbati o yi wọle o tun yi wọ iyara iya rẹ, ki o to jade, o jẹ akasu ẹkọ mẹfa nlanla. Iba jẹ ju bẹlọ ṣugbọn ẹkọ tan ni, jijade ti o si jade igbe ebi ni o nke eloyi ya gbogbo enia ati ara ilu lẹnu.

Laipẹ gbogbo ara ilu gbo, nwọn si bẹrẹ si sare wa wo o ṣugbọn inu ọmọ yi ko dun si wọn.

Nigbati o di ọjọ keje ti nwọn fẹ sọ ọmọ na lorukọ, awọn obi rẹ fi ilẹ pọn oti nwọn fi ọna r'ọka, nigbati o si to akoko ati fun un l'orukọ on papa dahun, o wipe Ajantala lorukọ mọ ibi ọbẹ gbodun, rukeru lo ọjọ na po jojo.

Nigbati Ajantala le wọn to bi o ti sfẹ, ni o pada si ilẹ, o bẹrẹ si powe o ni ṣe ẹ ni ẹ ko ni gbọn ni, emi ni yio kọ gbogbo yin logbọn. Bi o ti wi eyi tan, o wọ iyara iya rẹ lọ, o fọ awo mẹfa, nigbati o si tun jade si ita o tẹ adiẹ mẹfa pa.

Ọkunrin kan ti o duro lẹba ibẹ ni ha! ọmọde yi, ika ni ọ, Ajantala gba oluwa rẹ leti mẹfa, ibiti ayọrunbọ ọmọ na.

Ki a ma fa ọrọ gun mọ, titi, ọkunrin Babalawo yi nmura o wọ ṣokoto nla kan, lẹhin eyini o san bantẹ ogun le lori, lẹhin eyini o wa wọ agbada nla dudu kan, o de fila okiribi, o ko ogun sinu apo ifa rẹ awọn bi iko idẹ ado, atọ, ẹyọ owo, ilẹkẹ ti nwọn fi egun ejo ṣe ati orisirisi nkan bẹẹbẹ. o gb. apo ifa rẹ o di ile Ajantala.

Nigbati o de ohun, o Ajantala gba o sare agbada silẹ o fi ẹsẹ fẹẹ tẹlẹ o lee de ile rẹ gangan ki o to dehin.

Nṣe ni ara ọkunrin yi ri patipati, ṣokoto nikan ni o ku si idi rẹ. nṣe ni ọkunrin yi ngmi hẹlẹhẹlẹ.

Nigbati ọkunrin na de ile, gbogbo enia wa si ọdọ rẹ nwọn bere bi ohun titi, ọkunrin na dahun, o ni "ọran ọmọ na toto, ọmọ buruku patapata ni lati ọjọ ti mo ti de ile aiye, nko iti kan nkan ti o to ti oni ri, kini ọmọ na kose lan.

jona ẹ tun mbere irungbọn, moni o ti gba ohun gbogbo ti mo ni, ẹ tun mbere fila, ẹ ro pe bi mo duro ko ni gba ṣokoto mi papa ni.

A kii mọ ẹniti o ba ri i ninu yin ti ko ba tete sa oluwarẹ nfiku sire o. 'Bi ẹba si sa wale ngo ti yin sode nko le jẹki ẹnikẹni gbe ọran di mi mọle.'

Bayi ni Ajantala di ọran si ile ti iya rẹ kosi le fi ara da iyonu na mọ, o mu ọmọ buruku yi o di inu igbo, nigbati o de ọhun, o rọra fi ẹtan fi i silẹ iya na si ba ile wa, o ku ọmọ na sọhun.

Ibiti Ajantala ti nrin kiri ninu igbo ti o de ib kan ti awọn ẹranko marun ngbe pẹlu irẹpọ, orukọ ekini ni erin, ekeji Kiniun ẹkẹta Ẹkun, ẹkẹrin Ikoko ẹkarun Ewurẹ.

Ajantala bẹ wọn pe ki nwọn jẹ ki on ma ba wọn gbe, ki on ma ṣe iranṣẹ fun wọn, nwọn si gba bẹ fun Ajantala.

Lati ọwọ W. Williams

mi. Lati igbati nwọn ti nṣe onjẹ ni ọjọ ti a nwi yi ni ina ti nbi Ajantala.

Nigbati o si ṣe, o bọ si aghala nibiti nwọn ti nwa onjẹ, o mu Sibi (Spoon) o bẹrẹ si ro ọbẹ ti o wa lori ina, eleyi ya gbogbo enia ati awọn ti o wa nibẹ lẹnu, nwọn si bẹrẹ si wipe "Ọmọ ọ g ẹ d ẹ nipa ọrọdẹ Ajantala ni yio pa iya rẹ.

Kini Ajantala gbọ bẹ si, o wa pusan o ko bo gbogbo awọn ti nwa onjẹ, gbogbo nwọn ba tujade. Inu tubọ bi i, o bọ si ibiti awọn ti njẹ aṣe papa wa o ko pusan bo wọn, o na wọn o fẹrẹ pa wọn, ati gendẹ ati aghalagba gbiyanju ati da oju ija kọ ọ ṣugbọn aghara rẹ ju ti wọn lọ.

Nikẹhin olukuluku na ẹsẹ rẹ sọrọ, on na si sa ti wọn, gbogbo ẹpọpọ tu bẹyẹ, olukuluku nke pe Olọrun rẹ, awọn onigbagbọ npe Olugbala, Onimale ndaruko Anabi, elegun nkigbe egun, onisango npe sango, ọlọya npe ọya, ọjọ na ko dara fun awọn jaṣẹjaṣẹ ati awọn atọjule onati ọkunrin na si ti nja ẹnikan wa lati la wọn, Ajantala ta ẹni na ni ipa mẹfa, bi o ti ta ipa yi tan ni o ri awọn ti nwọn nta ayo, were o fi ija silẹ, o bọ si ibi ayo, o pa mẹfa, ẹgbọn rẹ ti o ri gbogbo nkan wọnyi, la ẹnu, o ni Ha! ẹnu ẹgbọn rẹ ya de ipakọ. Ajantala wa di ọran way.

BABALAWO ATI AJANTALA

Ẹnyin alagbara ọkunrin bayi ni ọmọ nla yi huwa lile di odidi oṣu kan gbako ti o si di ẹemọ si igboro ilu ti o di ijamba si ode ti ẹnikan ko si le mu.

Babalawo kan wa ni ilu yi, o jẹ ologun patapata gba, nigbati o ti ngbọ ọrọ ọmọ yi ni o ti bẹrẹsi fonnu, o ni kosi nkan ti o le nibẹ, o ni ayọrunbọ ni nitoripe bẹni awọn ayọrunbọ ma nṣe ati pe ni ọjọ ti on ba fi oju kan an, ohun gbogbo yio rọ. On yio si pa itu meje ti ode npa fun ba nibiti o gbe njẹun nigbati o si ki Ajantala tan, o joko ti iya Ajantala o mba sọrọ. Ohun ti o kọkọ ba ọkunrin yi lẹru nipe onjẹ ti o wa niwaju rẹ to ti enia mẹwa, okele rẹ kọkan si to teni mẹfa rigidirigidi lo ri. Kosi ẹniti o le ba Ajantala jẹun ki oluwarẹ yọ.

Ibiti ọkunrin yi lati iya ọmọ na ti nsọrọ nwọn daruko rẹ (Ajantala) kini Ajantala gbọ bẹẹ ṣe, o dide o gbe akasu ẹkọ kan o lẹ mọ ọkunrin yi laiya, o tun gbe ọbẹ ti o fi njẹun o da a le lori, ko si bẹru

Ajantala pa guru si o fun agbada mọ lọrun, o gba apo ifa rẹ, o ko bo o lori, o na titi apo na fi ja, nibiti nwọn ti nda reirei ka, o yi agbada mọ ọkunrin yi lori, o tu ibantẹ ogun idi rẹ, o kọ bo o.

Ẹnyin ara mi ati ẹnyin ara mi l'ọkunrin l'obinrin, nigbati ọwọ ba ọkunrin yi tan o fi igbe la, nigbati o jaja le yọ oei ninu agbada, o bọ

O lu mi bi ẹnipe ki nku, o fi iya jẹ mi bi ẹnipe ki nsalun, on fa mi ka bi ẹnipe ki o fi ori mi na apata. Ọmọ na fi oju mi kan nkan. Ọrọ na ya awọn ti o wa nibẹ lẹnu, nwọn ni, ohun ma kuku le o, ohun ti o ṣe ti Baba fi sa wale. Ẹ ko nsa ogun lọwọ ndan? Babalawo yi dahun o ni, ogun abi ki nla "oju ina ni ewura nhu irun."

Kini ẹ fi nṣe yi, ẹniti o na mi na mi ti o gbami lagbada, ti o fi ibantẹ ogun mi ṣe pasan na mi, ẹnyin ri apo ifa mi mọ, o ti gba ohun gbogbo ti mo ni patapata, ori lo yọ mi ti mo sare ero kekere kọ ni ọmọ na pa.

Ọkan ninu awọn tio wa nibẹ si tun bere lọwọ rẹ bayi pe Họwu! Baba, ẹwu awọtẹlẹ yin da? Baba yi tun dahun, oni oju ina ni ewura nhu irun, ọtun gba fila mi pẹlu.

Inu bi ọkunrin yi, o ni 'ẹ ye ibimi ni nkankinkan e ure' "baba

Ọkọkan ni awọn ẹranko wọnyi ma njade lọ wa onjẹ lojojumọ, bi ẹnikan ba lọ wa onjẹ awọn iyoku ajoko de e ni ile, igbati ẹniti o lọ wa onjẹ ba ti de gbogbo wọn a jọ jẹ.

KO TI PARI

Ran awọn ehin lowo
Da ehin didun duro

[illegible]

RA **Mendaco** lowo apogun loni.

Ma a ka Irohin Yoruba

"Eni maa jire ti ... ti o da Oloye Awol... jinki re. Eniti oba... titun ku ola ti orin... wa si Ben yio gba p... ariyọ, olol., agba at...

Orisa ajisa fun od... ni tewtagba fi wọ ... ti ro pe a bọ si Ir... Okunrin ati Obinrin... orin pe: "Ta lo sọ p... Bayi ni awọn ṣe fi ... Igboro Ibadan ni ọ...

Aworan oke yi fi a... gbe Oloye Awolowo...

Ayawonn wa, Jo... loju.

ITUM...

EYI ni lati kede ... ranṣẹ ti ko si ti jade ... nwọn mae bine, itu... ko gbagbe ẹnikẹni, n... ọdun o. Aṣeyi s'amọ...

Alabi Kutanga, Ilorin ... yi ṣugbọn ti o ba...

Phillip Olamuyiwa, Q... yio di pẹtẹlẹ fun...

Tiamiyu Faṣọla, Erek... ki ẹṣẹ ọlọrọ ma...

Kadija Ogunmọdẹde, ... ba dawọle lasẹko ...

James Kodaolu, Ofa— ... seko yi ṣugbọn ... gbọn ọn danu bi ...

Peter Famoriyọ, Ifẹ— ... kun fun adura.

Ronkẹ Williams, Lago... ma baa ṣe ọ ni j...

Fẹmi Talabi, Ibadan— ... okere wa ti yio ...

Abati Samuel, Ikorodu ... gidi.

Fi ala...

NOW–ROLLS-ROYCE 707s ON THE LONDON RUN



Eto irinajo ayarabiaṣa ti ojojumọ

NISISIYI oko ofurufu titun ti a npe ni Rolls-Royce 707 ti wa fun awon ero ti nlọ si Londonu ati awọn ile Oyinbo. Rolls Royce ti a mo jakejado aiye fun ero ti o dara julo li o se ero ti o ngbe oko ofurufu yi fo bi eiye. Fun igbadun ati itura nigbati o ba nrin irin ajo nínu oko ofurufu ayara bi aṣa, kesi Travel Agent re tabi ki o bere ni Nigeria Airways Booking Office ti o wa ni Broad Street, P.O Box 136, Lagos (Telephone 24811) bi ati Bank Road, P. O Box 11, Kano (Telephone 3891—tabi awon ile ise oko ofurufu ni agbegbe re.

"Eni maa jire ti ji re ki karo to ki". Orişa ti o da Oloye Awolowo da, o si fi awon ọjọ nlala jinki re. Eniti oba wọ Igboro Ibadan lojẹ odun titun ku ola ti orin lati Oke-Ado lọsi Ekotedo wa si Bere yio gba pẹlu mi pe Orisa nla akunle bo, ariyọ, olufẹ, agba ati olufẹ ewe ni Awolowo.

Orisa ajisa fun odun 1964 ni Awo. Oruko rẹ ni tewetagba fi wọ odun yi ni Ibadan. Bi agogo ti ro pe a bọ si inu odun titun ni ogunlogo Okunrin ati Obinrin ya eka igi lọwọ ti nwon si bẹrẹ orin pe: "Ta lo sọ pe ao ni baba "Awo baba wa". Bayi ni nwon ṣe fi igbe Awo! Awo! Awo! jo kakiri Igboro Ibadan ni ojo kini odun yi.

Aworan oke yi fi apakan han ninu awon enia ti o gbe Oloye Awolowo ga ni oru ọjọ na.

Ayaworan wa, Joseph Rotimi ni o danna si wọn loju.

ITUMỌ ALA

EYI ni lati kede fun awọn ti o ti fi ala wọn ranșe ti ko si ti jade ninu iwe Irohin Yoruba pe ki nwọn maşe binu, itumọ ala wọn yio jade laipẹ, a ko gbagbe ẹnikẹni, nșe ni a nto lẹsẹsẹ. Ẹ ku ewu ọdun o. Aşeyi ș'amọdun o.

Alabi Kuranga, Ilọrin — Idamu owo yio ba ọ laipẹ yi șugbọn ti o ba ni suru, nkan yio dara fun ọ.

Phillip Olumuyiwa, Ọtta — Gbogbo oke işoro rẹ yio di pẹtẹlẹ fun ọ laipẹ yi.

Tiamiyu Fașọla, Ereko Lagos — Șọra nipa akowaba ki ọrọ ọlọrọ ma ba di di tirẹ.

Kadija Ogunmọdede, Abẹokuta — Ohunkohun ti o ba dawọle laseko yi rere ni yio jasi.

James Kodaolu, Ofa — Nkan rere yio tẹ ọ lọwọ laseko yi șugbọn șọra lọdọ ọrẹ ki nwọn ma baa gbọn ọ danu bi ọgan.

Peter Famoriyọ, Ifẹ — Ajẹ ndọdẹ rẹ lati șe ọ ni ibi kun fun adura.

Ronkẹ Williams, Lagos — Șọra ki awọn orogun rẹ ma baa șe ọ ni jamba.

Fẹmi Talabi, Ibadan — Iwọ yio gbọ iro rere lati okere wa ti yio șe ọ ni anfani.

Abati Samuel, Ikorodu — Ọta ndọdẹ rẹ șọra gidi-gidi.

Fi ala rẹ ranșẹ si

Joseph Alala

Irohin Yoruba

Tribune Office

Ibadan.

Yoruba Parapo

Lati oju ewe kinni

tako nyin nitoripe ẹnyin ni olusagbtan ofin ti ko gbọdọ ni ojusaju.

"Ẹgbẹ Afẹnifẹrẹ ko bẹru gbogbo apapọ awọn kotonkan ẹgbẹ Alakukọ ati ẹgbẹ ọlọmọ-langidi ninu apapọ ẹgbẹ oşelu kan wọn.

"Ẹgbẹ Afẹnifẹre ni ireti kikun lojọ ọla, papa ireti gigoke alọ ni akoko ibokibo"

EGBE KAN

Adele Ẹgbẹ Afẹnifẹre na sọ pe gbogbo awọn enia ti o pe ipade yi sọ pe "idi ti nwọn fi pe ipade na ni lati pari awọ ti o wa larin Ẹgbẹ Ọmọ Yoruba ati Ẹgbẹ Ọmọ Oduduwa, șugbọn "idi ti nwọn șe nșe ipade na ko ju lati pe awọn ọmọ ẹgbẹ Alakukọ, Afẹnifẹre ati Ọlọmọ-langidi pọ si ẹgbẹ kan fun idibo si ile Igbimọ Asofin Iwọ Orun ni akoko ti o ba ya."

Awọn idi miran ti Ọgbeni Ige tun fi ẹnu kan ni:

5 "Lati le ri aye fi siwaju pe ẹgbẹ Afẹnifẹre ni ko fẹ apapọ ọmọ Yoruba ti nwọn ba kọ lati lọwọ ninu ipinnu wọn na;

x "Lati le wa ifẹ awọn Ọba ati awọn Adajọ kotu giga, ki nwọn si le mu wọn gba pe, laijẹ wipe nwọn pa Ẹgbẹ Afẹnifẹre rẹ, ẹgbẹ olomi Ariwa "ko ni ran awọn ọmọ Yoruba lọwọ"

Ọgbẹni Ige si sọ siwaju pe awọn ọmọ ẹgbẹ Alakukọ, Afẹnifẹre ati Ọlọmọlangidi jankanjankan ni Ẹko șe ipade kan lori ọrẹ na ni Ẹko ni ọjọ keji o.u kini ọdun yi.

ISELU

O fi han pe awọn ti o pe ipade na ko fi han ninu iwe ipe ipade wọn ohun ti nwọn fẹ șe ninu ipade na.

Ọgbẹni Ige si tẹpẹlẹmọ ọrọ rẹ siwaju pe, ipade ti Ibadan jẹ ọrọ iselu nitori lati wa ẹgbẹ iselu kan fun awọn ọmọ Yoruba ti yio maa jẹ Ẹgbẹ ọmọ Yoruba Parapọ (Yoruba United Front) ni nwọn șe pe ipade na.

O si la kedere pe ẹgbẹ Afẹnifẹre ki ba ti kọ ibi ara si wọn rara bikoșe nitori koko ọrọ kan pataki.

"O si wa șe ibere pe," "Ewo ni o ton kan ti awọn Adajọ ninu ọrọ iselu ?

"Tabi eyi jẹ ero awọn akẹgbẹ Yoruba Parapọ na jọ lati sọ awọn adajọ di oniyẹyẹ ati ẹran rogbodiyan iselu ?

Ọgbẹni Bọla Ige si fi han ni ipari ọrọ rẹ pe. Ẹgbẹ Afẹnifẹre ko jẹ ba ẹnikẹni lọwọ ninu ẹgbẹ aladamọ ati oniyẹyẹ.

"Ẹgbẹ Afẹnifẹrẹ ko ni kọ ẹhin si ẹgbẹgbẹrun ọkẹ aimoye awọn alatilẹhin rẹ ni orilẹede yi lailai bẹni Ẹgbẹ Afẹnifẹre ko jẹ pokunso ninu iselu ki nwọn si fi awọn akikanju asaju wọn le awọn alawọpa lọwọ nitori ifẹ ara eni ti o wa fun iwọn igba diẹ".

ITUMỌ ORUKO OLOYE ỌBAFẸMI AWOLỌWỌ

OBAFEMI

Ọ — Ọlọrun gba mi nipa orukọ rẹ.
B — Buburu kan ki yio șubu lu ọ.
A — Awọn ete eke ni ki a mu dakẹ.
F — Fi ọna Rẹ han mi Oluwa.
Ẹ — Ẹsẹ mi duro ni ibi titẹju.
M — Mașe fa mi lọ pẹlu awọn enia buburu.
I — Igba mi mbẹ lọwọ Rẹ, gba mi lọwọ awọn ọta mi.

AWOLOWO

A — Awọn ti o si nfi ibi san ore ni ọta mi.
W — Wa ẹnyin ọmọ, emi o si kọ nyin ni ẹru Oluwa
O — Oluwa Iwọ o ti ma wo pẹ to ?
L — Lọwọ Rẹ ni mo fi ẹmi mi le
Ọ — Ọlọrun pa mi mọ nitori Iwọ ni mo gbẹkẹle
W — Wo ipọnju mi ki O si gba mi
Ọ — Ọlọrun nikan ni ọkan mi duro jẹẹ de.

J. A. Adegbami
MASIFA — EJIGBO.

Nibo ni iranlọwọ mi yio ha ti wa?

Ọdun dun. Nibo ni Iranlọwọ yin yio ti wa? Lati ọdọ ọrẹ; lati ọdọ Sango ni; tabi lati ọdọ Ọya; ọdọ Ifa; lati ọdọ egbogi; lati ọdọ Orisa ni; nipa agbara rẹ; tabi Ọgbọn ori rẹ; lati ọdọ aya ni tabi ẹbi rẹ ni?

Niwọn igbati a mọ pe igbẹkẹle enia asan ni; ati pelu pe ọwọ ẹpo ni Ọmọ araiye nba ni la, won ki nba ni la ọwọ ẹjẹ. Ara mi ninu Oluwa ndi, oni lati ronu ẹniti o ti pinnu lọkan rẹ pe iwọ ko ni ki mọ lailai.

Iwo ko gbodo se Pansaga

Bẹni iwọ si gbọdọ ronu nipa iwa Pansaga ati agbere ti o ti șe, oni lati ronu nipa iwa ọdalẹ ti o hu, oni lati ronu irọ, eke ati ofofo ti onse, oni lati ronu eni ẹleni ti o ti pa saiye ti o ko pa șorun, megida ti o sọ di mehaya, gbogbo silẹ, ki o si pinu pe iwọ ki yio șe mọ. Jesu Kristi wipe Bikobașepe atun enia bi on ko le ri Ọlọrun. (John 3:3).

Nigbayi ni aiye rẹ yi o tor. bi omi ọmu, ni gbayi n ibanujẹ rẹ le di ayọ, nigbayi ni owo ati ọmọ yio fi ọna ile rẹ șe ọna lati ba ọ gbe.

Igbagbo re mu o larada

Bi a ba ni Igbagbọ pe Ọlọrun nikan ni oluranlọwọ olododo, ki a bẹrẹ si igbe aiye mimọ, iwa ọtun. Ki ohun rere lọtun-lọtun le ma wọle tọ wa ninu ọdun titun yi, ki ibukun Ọlọrun alafia ati ẹmi gigun ki o ma ba yin gbe.

IRANLOWO MI YIO TI OWO OLUWA ENITI O DA ORUN ON AIYE. (Orin Dafidi 123: 2) nitorina bẹrẹ si șe rere lati oni lọ, ki re re le jẹ tirẹ ninu ọdun yi, nitori Ọlọrun ki șe ojusaju enia. Alafia fun yin (Amin)

Lati ọwọ O. Aiyelabọla

NIBO NI IRANLOWO RE YIO TIWA NINU ODUN TITUN YI?

Iranlọwọ wa yio ti ọdọ Ọlọrun wa ẹniti o da Ọrun on aiye (Orin Dafidi 123: 2) Bi idaniloju ba wa fun gbogbo awon Onigbagbọ pe Ọlọrun Ẹleda nikan ni Oluranlọwọ ododo, Ọba awimayẹhun, ọyẹ ki a sunmọ Ọlọrun na pẹkipẹki, ranti pe Ọlọrun ki gbe ibi eri, Ọba mimọ ni on nșe.

Odun titun ohun titun

Ni akoko ọdun titun ni gbogbo awa Onigbagbọ wa yi, ọdun titun ni a șeșe bẹrẹ si, o si da mi loju pe. Olukuluku ti parọ așọ ti ọdun to koja, ti ati ra așọ titun șokoto titun, bata titun, elomiran kun ile rẹ lẹfun.

Ani lati ronu gbogbo Isẹ ọwọ wa, gbogbo jibiti ti a lu, ẹnikẹni ti o ti palẹkun, oni lati ronu nipa owo abẹtẹlẹ ti o gba, iwọ agba lọwọ meri. Onilati ronu ẹri eke ti o ti gbe alaișẹ, onilati ronu ole ti o ja, oni lati ronu ọtẹ ti o oni lati ronu ẹjọ ẹlẹbi ti o ngbe fun alare, labẹ ile, nibi ișe, ati ninu gbọngan idajọ.

O nilati ronu ișẹ isin si aladugbo rẹ. Nigbati gbogbo ohun eri ati iwa ẹșẹ wa lọkan rẹ, o ko wẹ won nu kuro, iwọ ko yi ipinu lati kọ awon iwa ẹșẹ yi sile "Kaka ki o san ara iya ajẹ nșe ni o tubọ nfi ọmọ rẹ bi obirin".

Gbogbo inu ati ọkan rẹ kun fun iwa ika, Ibateni ẹleni jẹ, afojudi, eyin ha ro pe Ọlọrun a ma gbe ibi idọti ba wọn yi? Bi o ba nfẹ iranlọwọ tire ti ọwọ Ọlọrun Ẹleda wa ninu ọdun titun yi, Ọba ti ti o ni ohun rere gbogbo lodu-lodu ti nșe Olodumare.

IRONU PIWADA

Bi iwọ ba nfẹ owo ọtun, ipo giga ọtun, ọla ọtun, ọmọ ọtun, alafia ọtun, ibukun ọtun ninu ișẹ rẹ, ẹmi gigun ọtun, ninu ọdun titun yi.

Ara mi, o ni lati ci atunbi ninu iwa ati ișẹ rẹ, oni lati kọ iwa ẹșẹ

Iwasu șe pataki

KỌ ARA ILE RẸ LẸSIN

Salamu alaekun fun gbogbo ẹnyin olugbagbọ ododo, Iwasu mi ọsẹ yi duro lori "IWASU SE PATAKI" gẹgẹbi Oluwa ti sọ fun Anabi wa Muhammed (S.A.W.A) ninu Qurani mimọ Suratu 87 Aale aya 9-10 ọka bayi pe:- koro nipa Isin Ọlọrun ati sisin ẹsin na pelu.

Jeki oran ọ leti. kosi da ọ loju gbangba pe, nigbati Olorun ran Anabi wa Mohammedu (S.A.W.A) ni isẹ, ẹniti oko fi ẹsin na kọ gan ni Adijatu Iyawo rẹ, fi eleyi kọgbon, ko mọ pe

Lati ọwọ Alfa Abdulibaki Mohammed Iwo.

Wasu anfani wa ninu sișe Iranti; Iyawo yio taji olubẹru, Iọwọ Iwọ Olugbagbọ ododo, kiyesi lilo ofin inu aya yi dada. Emi ati Iwo kajọ gbe ẹwu iwasu ododo, lẹtọ wọ, fun igba ara wa ati ẹmi wa kuro lọdọ esu ẹni ẹkọ.

Ki ise fun ara wa nikan, fun awon Iyawo wa, Ọmọ wa, Baba wa ati Iya wa, omo Iya wa, ara Ile wa, ara adugbo wa, Ilu wa, gbogbo aiye, ko jẹki awon talaka yi ri imọlẹ Imọlẹ Olorun Ekọ toye kikọ awon Iyawo rẹ, ati awon omo rẹ ni ẹsin jẹ ọranyan, kinni ki oto wakan iwasu așe gbowo ti o nșe kiri.

Sora, sora gidigidi ki oma se jẹ fitila ti okunkun wa ni idi rẹ ti si nse imolẹ fun awon omo enia, Iwọ mura ki ọjapa ati lo ofin Olorun, ki o si ka si eti gbọ. Awon omo enia, eniti oba fẹ kose, ati eniti ọsere ati ẹniti ko sere ni ao ko pade niwaju Olorun.

Oluwa ko șe wani olorire laiye ati ọrun o *Amin o.*

Classfied Advert

OGUN FUN JERUNJERUN (SEBENOL HAIR GROWER — Vitamin B. Oogun irun pelu agbara aranse lori irun ti inuja ti ofe so enia di alayi ni irun lori, o ngmu ISAKA kuro lara, nkan gbigbona ti oba dajo oma lara, EKUSA, O tun afun awon irun ti onse irun ni okun lati dagba pelu ilera, agbara ati wipe ki irun lepon. Igo kekere 5s 6d, Igo nla 25s. RHUMAQUINOLINA nse aranse lori bi nkan gbigbona dajo enia, Isaka, Ekusa, o tun ngmu ilowisaja ba Irun si ayekaye yowu ki irun lewa. Igo kan 4s 5d, (POSTAGE) Owo ifiranse lọtọ. Kowe tabi ki o wa si ENANG & COMPANY Box 2763, 30 ODUNLAMI STREET, Phone 25636 LAGOS Ante Asoju ni gbogbo ile NIGERIA fun ere apa oni ti oba fe.

IKO-FEE

TI DI ONA-OFUN OJO KANNA NI YIO DE

Ara re nwẹ omi-aisan kokoro, arun ati panti oloro jade kuro ninu eje re lati inu adota-leniriniwo-oka iho kekeeke tabi awon ase ti o wa ninu Erse (Kidney) re. Bi awon oro ti o wa ninu awon Erse (kidney) tabi Apo-ito re ba nfi iya je o nipa tito ito rukuruku. "TI O SI NTAJI LORU LORU TI LAKUREGBE nyo e lenu, ti bebe isale oju re ba wule, ehin didun ti gbogbo Isepo ara ba nro o ti ise ba ojo o nidi, bere si fan Erse inu re lowo nipa lilo CYSTEX loni. CYSTEX ma a bere si ise lehin wakati meta, kiakia ni yio si wo gbogbo irora re san ti yio si mu o lara da, a seleri ati da owo re pada ti ko ba ri be. Bi apo-ogun re lere.

Cystex loni fun Erse (Kidney) Lakure' gbe.

OLOTU MI ỌWỌN

Ọpẹrẹkẹtẹ adamọ ndagba inu mbajẹ

Emi ni L. LASISI
Ebute-Metta, Lagos.

Olotu, jọwọ gba mi laye ninu iwe rẹ oloyin mọmọ lati kesi Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun pe, kini ole fa lati ti omi agbegbe Ijebu Rẹmo? Tabi nitori oleri Ọlọmọlangidi ti o wa si Ṣagamu ti awọn ọmọ ile iwe peni "OLE"; NI.

Orukọ ti o yẹ wọn gan ni wọn pe wọn. Ko ni lati binu. Awa ko bẹ yin rara lati si omi, ti ẹ ba fẹ ki ẹ si ti e ko ba fẹ ki e ma si mo si gbo pe ki wọn to si omi awọn obintin AGBE-GBE-IJEBU-REMO gbọdọ ma san owo ori.

Rara awa ko gba yen, sugbọn fun awọn ọmọ Ijebu ati ọmọ Yoruba o to asiko ti a gbọdọ ko ara wa ni ijanu.

Ẹfẹ, e kọ, AWỌ ni baba

Modupe Olotu,

Tiwa ni Ẹgbẹ ọlọpẹ

Olotu, mo dupẹ aye ti ẹgba mi ninu iwe yin oloyin mẹmọ lati sọ fun awọn ọmọ ẹgbẹ amusua wọnyi pẹ Ọpẹ lori West!

Ẹni ba mọyi wura la nta fun ẹgbẹ to ṣe gẹgẹ awọn ara Ipinlẹ yi ni ẹgbẹ ọlọpẹ.

O ya mi lẹnu lati ri wipe o ti han si wa pe ẹgbẹ UPP ti di ẹgbẹ olomi (NPC) Ahmadu Bello lo sọ bẹ ki o to se abẹwo se abẹwo ilu okere laipẹ yi nitorina mo bẹ ẹnyin ẹgbẹ Alakukọ ki ẹ mase ba ẹgbẹ buruku, ẹgbẹ ole ẹgbẹ ọdalẹ yi se pọ, nwọn fẹ ta Ipinlẹ Iwọ Orun fun awọn Gambari.

O ti daju pe lọjọ idibo Ọpẹ ni yio wọle nitori ife ti nwọn ni sii, Ẹ mase dibo fun ẹgbẹ akotileta, ẹgbe alakokoro Ẹ dibo fun ẹgbe Ọlọpẹ.

(Emi ni Ọmọ West)
Ibadan.

Ipilẹ Ẹgbẹ Alakukọ Bajẹ

Ẹ JỌWỌ ẹ gba mi laye lati kesi awọn ọmọ Yoruba ninu iwe yin oloyin-mọmọ ti o njade lọsọsẹ wipe, asiko to wayi ti o yẹ ki awọn ti o wa ninu (N.C.N.C.) ẹgbẹ oniyọrọ

DOKITA OKPARA

Ti ori balẹ fun Baba Isalẹ Ẹgbẹ Afẹnifẹre Oloye Obafẹmi Awolowo ati Adele rẹ, Oloye Alhaji Dauda Shoroye Adegbenro, nitori owe awọn agba ti o sọ wipe "Eni ti o ba sọ ile nu, so apo iya kọ."

Enyin ko gbọ ọrọ masasi Ọgbẹni kan nsọ si Ọgbẹni kan wipe ko gbọ ede Oyinbo to on, ati wipe o'oye na kere si on pupọ lọna gbogbo, eleyi sele ninu ẹgbẹ kanna, eyi ti o baru jai larin ẹgbẹ sẹgbẹ.

Ṣe inu ẹgbẹ ti nwọn ti nmọ elebu ara wọn yi na ni ẹnyin ti ẹ jẹ ojulowo ọmọ Yoruba lẹ ku si? Diẹ ni eleyi, ọrọ agb banujẹ ko ni sai waye ti ẹ ba tete na sinu ẹgbẹ Afẹnifẹre ti Oloye Obafẹmi Awolọwọ.

Ẹgbẹ nfẹ rere fun Ipinlẹ Yoruba pataki julọ Ilẹ Naijiria.

Ẹgbẹ Afẹnifẹre iwaju ni ẹla yin yio ma lọ.

Emi ni tiyin
Ọmọ-Ọba R.O.S. Ọlaluwoye
LAGOS.

Ẹgbẹ Ọlọpẹ yio goke Alọ

Inu mi yio dun bi olotu Iwe Irohin Yoruba ba le gba mi laiye oro mi bi meji tabi meta.

Modupe lowo olotu Irohin Yoruba fun gbogbo isẹ to ti nse lati ọjọ yi, Ọlọrun Olodumare yio jẹki o dara fun o. Oluwa Ọlọrun yio gbe wa leke awọn ẹgbẹ Ọlọmọlangidi pelu awọn oniyọrọ.

Mo bẹ enyin omo egbe Afẹnifere ni Ile Naijiria pe ki Ẹ fi ori ti isoro ti ẹgbẹ na ko si, tori "bi a o ku Ireti ko pin" Ọlọrun yio gbe Baba-Isale Ẹgbẹ wa leke awon ota. Amin.

Ki eje ki ese nyin duro ṣinṣin o nitori pe "oba ni ko, iti bajẹ" ṣugbọn Ọlọrun Olodumare ti kisarẹ ni yio tun gbe wa dide.

Eme ni,
S. T. Odẹyẹmi
Ikoromọja

OKEHO KỌ ADELỌDUN

Pataki ọrọ mi ni pe mo fe ki ẹ tete ba mi tẹ iwe yi fun gbogbo aiye ka. Awa egbe Afenifẹre ko se ẹgbẹ UPP. Ni ọjọ ti Adelodun ati Taiye wa Ilu wa lati wa se aroye fun wa wipe ki a ṣe ẹgbe UPP, awa ko gba ọrọ won tori awa wa lehin Oloye Awolowo titi di ọjọ iku wa.

Awon papa kan abuku jade ni inu Ile Ọlọrun ni. Igbati o di ọjọ keji gbogbọ egbe Afẹnifẹre ni nwọn bu, nwon si nsọ pe awa ko ni fi egbe Afenifẹre silẹ o. Bi ekun ba pẹ titi ayọ mbọ lowurọ. Ṣugbon idibo lawa nreti o.

Taiye ati Adelodun purọ, wipe ko si idibo mọ sugbọn nwọn tun ja ara won nibẹ lọjọ na o. Awa nfẹ Ijọba rere ni kiakia, to ri aiti owo na npa wa ku lọ o.

Ọrọ wa ko lopin siyin. A ki awọn ẹbi Sumbọ Jibowu, Ẹ ku ọfọ Sumbọ o. Oluwa yio da awọn ọmọ rẹ sio.

Okeho Egbe Afenifere

Awọn ọna atunse wọnyi nfẹ

INU mi yio dun ti ẹ ba le gba mi ni aye lati ẹrọ mi bi gbolohun meji jade ninu iwe irohin yin.

Ekini — Eyi si ni lati ke si ijọba Gusu Ilesha I.S.D.S. lati ba wa mojuto ọna wọnyi. Ilọba, ti o jade si Oke-bode ati Ila lọ de Ilesha.

O jẹ ọrọ ti ko ṣe gbọ rara lẹhin igbati awọn enia ti o wa ni ọna yi ti tun san owo ori wọn tan, tabi ki nwọn tun ma da owo miran laye ọrọ fun ati nje ọna ... wa nile lati tan ...

O tun jẹ aramanda lati gbo wipe ibiti ọkọ ti nde tẹtẹ ri ko tun ni anfani ati de ibẹ.

Gẹgẹ bi enia eleran ara, ọ yẹ ki a ma ṣe gbogbo nkan dogbandogba lasi ituje lọna kan ju ona kan lọ.

Idi pataki ti o fi yẹ ki Ijọba ISDC mojuto ọna yi ni wipe owo ori mbọ bayi, ẹranyan si ni fun gbogbo enia lati wipe ki awọn agbegbe wọnyi san ti won laiko ni si iboju wo ẹhin rara.

Sugbon nkan ti e mo pe o jẹ anfani ti awọn enia wonyi ni ki e lọ joko ti, ki ẹ lo ro wo, nigbati opolopo nkan anfani ti won ni ni e ko se fun won.

Eyiti o ṣe pataki ni oju ona won yi, tabi obinrin miran ti o ba nrobi omo ti ko ba tete ri moto ti yio gbe lọ si ile-iwosan, ti nwon ko si le fi ese rin rara lasiko ti ara won ko da yen.

Nje kini iyori si aisan ati irobi na ma yori si? Ṣe a npo si ni yen tabi a ndi si?

Ejọwọ ẹ gba eyi ro, temi gege bi enikan nso tedun tedun ọkan mi lati mu ki awọn nkan pada bo si ipo won lori wipe ki Ijọba ti o ni awon ona wonyi Ilọba, onikoko, Osin ati Ila lo de Ilesha se atunse won laiko nipe rara.

Nitori nkan ti onwọle fun Ijọba lọna yi gan, ni koko, owo ati awọn nkan an'ani bẹbẹ lọ pọ ju wipe ki ẹ ba wa fi oju da agunla lori awọn ona wọnyi.

Ẹ jọwọ, e ba wa se eleyi, ki o to di ọjọ pipe, nitori ko si ọbọ kan mọ ni ibikan o. Eleyi ti oku sibẹ ẹwu ẹtu lo nwọ o.

Ona wọnyi jẹ ọrọ ẹdun ọkan ẹnikọkan ni ilu wọnyi o. Ti yio si jẹ ki awa na kọ Hawuo ni ọjọ iwaju o, Ẹjọwọ ẹ gba ro kankan o.

ILESHA
L. B. Ogunniyi.

Gedegbe ni owo Redio Erinmope fo

Inu mi yio dun bi olotu ba le gbemi laye ninu iwe rẹ oloyinmọmọ lati fi ye awọn enia wa wipe ko si owo kankan ti apinjẹ.

Ọpọlọpọ enia ni nwọn nkun wipe gbogbo owo Redio ti awọn enia da jọ ni gbogbo wa ti pin na. Ọpolopo enia lo si wipe awa to wa lẹnu owo na ni o mọ nipa owo na ati papa julo Iro patapata gba a ni eyi.

Emi si fi ye yin wipe gbogbo owo ti ẹ da silẹ ni o wa ni ipamo ko si eniti o fowọ ba owo yin o.

Ẹlomiran tilẹ nfi yeni wipe owo na ni opolopo ma gbojule lati fi ra asọ ati lati fi se ọdun keresimesi.

Mo si bẹ enyin Ijọba wa ki ẹ ba wa tete se amojuto ẹrọ Redio na ki awon enia ma ye sọ isokuso siwa.

Mo dupe aye ti ẹ gba mi. Iwaju ni owọ yin yio ma lo o.

Emi ni
Z. A. Daramola
Erinmope - Ekiti

KINI IRAWỌ WI ?

Mase kọ eti odi si ohun ti irawọ rẹ wi ninu ọsẹ yi nitori igbọran san ju ẹbọ lọ.

AQUARIUS (Jan 10-Feb. 18) Iwọ yio ri abayọrisi rere ninu ero ati ninu Iṣẹ rẹ gbogbo ninu ọsẹ yi.

PISCES (Feb 19-March 20) Pẹlu ẹkun rere ilera ati opolopo ayọ ni Iwọ yio fi bori awọn isoro ti o yiọ ka. Iwọ yio si leke ninu ohun gbogbo ninu ọsẹ yi, sugbọn sọra fun inu fuufu.

ARIES (March 21-April 19) Iwọ yio ri ere pupọ jẹ laseko yi lori iṣẹ rẹ ninu ọsẹ yi.

TAURUS (April 20-May 20) Iṣẹ pupọ yio bọ si ikawọ rẹ lati ṣe ninu ọsẹ yi, sugbọn sọra gidigidi ki a ma ti ipa ọrọ mu ọ binu.

GEMINI (May 21-June 20) Maṣe fi akoko ṣere ninu ọsẹ yi nitoripe iṣẹ pọ ni Iwaju rẹ ma si ṣe faye silẹ fun inu fuufu ki gbogbo iṣẹ rẹ le maa ṣe deede.

CANCER (June 21-July 20) Inu ọsẹ yi jẹ asiko dada fun ọ lati rin irin ajo. Iwọ yio ni ayọ ati igbadun pupọ lati bẹ awọn ọrẹ rẹ wo. Iwọ yio si ṣe orire nitoripe iwọ yio ṣe alabapade ẹnikan ti wọ ti nfẹ ri.

LEO (July 21-Aug 22) Iṣẹ pupọ mbẹ ni ikawọ rẹ hitori na faramọra ki o ṣe ọkan giri ki o si fi itara ṣe awọn iṣẹ na nitori Iwọ yio ri ere lori iṣẹ na ju bi o ti ro lọ.

VIRGO (Aug 23-Sept 23) Iwọ yio ri ilera ninu ose yi. Iwo yio si ni ayo kikun lati fi tagbaratagbara ṣe awọn iṣẹ ti Iwo ti sati mọṣe iwanwara pupo masi ṣe gbẹkẹle enia ki nwon ma baa tan o jẹ.

LIBRA (Sept 24-Oct 23) Iwo yio sepa awon isoro rẹ nipa owo ninu ose yi kun fun adura, agbekẹle rẹ ki yio ja si asan nini ose yi.

SCORPIO (Oct 23-Nov 21) Maṣe tipẹlẹmọ iṣẹ pupo ninu ose yi ki lala iṣẹ ma baa gbe ọ lugbode aisan. Kun fun adura nitori ibinu.

SAGISTARIUS (Nov 22-Dec 21) Iwo yio ri aye itesiwaju pupo ninn ose yi Bakanna ni Iwo yio si ri itẹlorun pupo ni ibi iṣẹ rẹ ninu ose yi.

CAPRICORN (Dec 22-Jan 19) Iwo yio tete lugbadi arẹ ni ibẹrẹ ose yi nitori iṣẹ ko ni lo gẹgẹbi Iwo ti ro. Kun fun adura ki o si ko ohun gbogbo fun Ọlọrun fun iranlowo.

Rorẹ ati Awọ-ara fi ko dara yio san larin wakati merinlelogun

NIXODERM

ỌJỌ ỌJA ILẸ YORUBA

I L U	OJO 'RU JAN. 8 (WEDNESDAY)
Eko Ati Agbegbe Re	Mushin, Badagry
Abeokuta	Otta Abalabi Sodeke Omida Ilawo —
Ibadan	— — — — — — —
Ijebu	— — — — — — —
Ijesha	Oshu Itagun Odogbo Idoko Iloko
Ondo Ati Eti Odo	— — — — — — —
Egbado	
Ogbomosho	Araromi — — — —
Ekiti	Oke Aiyedun
BINI	— — — — — — —
Eti Odo	— — — — — — —
Igbajo	Iloro — — — — —

I L U	OJO 'BO JAN. (THURSDAY
Eko Ati Agbegbe Re	Agege, Ikeja Ikosi, (Epe).
Abeokuta	Lafenwa Obada Oba Kajola Ajegunle
Ibadan	
Ijebu	Ikenne Okun-Owa Erunwon Omu Mamu Ibefun, Atikori, Imushin, Ago-Iwoye, Ijesha-Ijebu. Isara Imodi
Ijesha	Esa-oke, Ilase, Epe, Iloba, Iperindo, Imuroko, Ikeji.
Ondo Ati Eti Odo	Igbo-Egunrin
Egbado	— — — — — — —
Ogbomosho	Oko ——————
Ekiti	Oke mesi; Ifaki; Igede; Ikole
BINI	Iromi
Eti Odo	— — — — — — —
Igbajo	— — — — — — —

ILU	OJO ETI JAN. 10 (FRIDAY)
Eko Ati Agbegbe Re	Oyingbo.
Abeokuta	Atan, Agbado, Ifo, Itori, Itoku, Isabo,
Ibadan	Olode
Ijebu	Aiyepe, Sagamu, Itaosu, Ogere, Isele, Ita
Ijesha	Ibodi Ibode Kajola
Ondo Ati Eti Odo	Oka, Ilora.
Egbado	Alagba Ilaro — — — —
Ogbomosho	— — — — — — —
Ekiti	Ilogbo, Ishan.
BINI	Eke
Eti Odo	Kpaksang, Bomadi, Ekeremor, Tonigbene
Igbajo	

I L U	OJO ABAMETA JAN. 11 (SATURDAY)
Eko Ati Agbegbe Re	Obun Eko — — — —
Abeokuta	Ijoko Iberekodo Asu Wasimi —
Ibadan	Ijaiye-orile, Fodegbo, Oyelesa, Egbeda
Ijebu	Ilishan Odogbolu Atan Imope Ishan Isara
Ijesha	Iwara, Ejioro, Odo, Ibokun, Esa-Odo,
Ondo Ati Eti Odo	— — — — — — —
Egbado	— — — — — — —
Ogbomosho	— — — — — — —
Ekiti	Egosi, Odo-Aiyedun.
BINI	— — — — — — —
Eti Odo	Kokori
Igbajo	— — — — — — —

I L U	OJO AIKU JAN. 12 (SUNDAY)
Eko Ati Agbegbe Re	Mushin Badagry
Abeokuta	Otta, Abalabi, Sodeke, Omida, Ilawo.
Ibadan	Oja-oje
Ijebu	— — — — — — —
Ijesha	Oshu Itagun Odogbo Idoko Iloko
Ondo Ati Eti Odo	— — — — — — —
Egbado	— — — — — — —
Ogbomosho	Araromi — — —
Ekiti	Oke Aiyedun
BINI	
Eti Odo	— — — — — — —
Igbajo	Iloro — — — —

I L U	OJO AJE JAN. 13 (MONDAY)
Eko Ati Agbegbe Re	Agege Ikeja Ebute Ero Ikorodu
Abeokuta	Lafenwa, Oba, Obada, Kajola, Ajegunle
Ibadan	————————
Ijebu	Ikenne, Okun-owa Erunwon Omu, Mamu, Ibefun Atikori Imushin Ago-woye Ijesha
Ijesha	Esa-Oke Ijebu-Ijesha Ilase Epe Iloba Iperindo Imuroko
Ondo Ati Eti Odo	— — — — — — —
Egbado	— — — — — — —
Ogbomosho	Oko — — — —
Ekiti	Oke mesi Ifaki Igede Ikole
BINI	Uromi
Eti Odo	— — — — — — —
Igbajo	— — — — — — —

I L U	OJO ISEGUN JAN. 14 (TUESDAY)
Eko Ati Agbegbe Re	Oyingbo — — — — — — —
Abeokuta	Atan Agbado Ifo Itori Itoku Isabo Odeda
Ibadan	Olode
Ijebu	Aiyepe Sagamu Ita osu Ogere Irolu Itele
Ijesha	Ibodi Ibode Kajola
Ondo Ati Eti Odo	Oka, Ilara.
Egbado	Alagba, Ilaro
Ogbomosho	— — — — — — —
Ekiti	Ilogbo Ishan
BINI	Eke
Eti Odo	— — — — — — —
Igbajo	————————

ILU	OJO 'RU JAN. 15 1964 (WEDNESDAY)
Eko Ati Agbegbe Re	Obun-Eko.
Abeokuta	Ijoko, Iberekodo, Asu, Wasimi, Araro-
Ibadan	Ijaiye-orile, Fodegbo, Oyedeji, Egbeda,
Ijebu	Ilishan Odogbolu Atan Imope Ishan
Ijesha	Iwara, Ejioro, Odo, Ibokun, Esaodo
Ondo Ati Eti Odo	— — — — — — —
Egbado	— — — — — — —
Ogbomosho	— — — — — — —
Ekiti	Egosi, Odo-Aiyedun.
BINI	— — — — — — —
Eti Odo	Kokori — — —
Igbajo	— — — — — — —

ALAPARA IBADAN

(Lati oju ewe keji)

arunmẹra, aiye ti su u, ọrun ko se gba lọ fun un ni.

Alapara: Olotu, o yẹ ki a maa se rere ki igbẹhin wa ba le dara o.

Olotu: Oko mọ bẹ ?

Alapara: Nigbati o di agogo mẹfa abọ irọlẹ ni nwọn gbe ere baba Layinka jade pelu agbada leesi lọrun ati fila "Awo" ti o jinna lori pelu dansiki t'oke t'ile ti o jire ati "Kọfin Shuu" atata lẹsẹ pelu "sipetikuru" ti o dara loju. Ogunlọgọ enia beresi kigbe Awo! Awo!! Awo!!! A.G. on top.

Olotu: Kini tun sẹlẹ si ere Akatanla ?

Alapara: Nje ni nwọn da ina sun, bi o ti njona ni nwọn nlẹ Fokuta titi o fi jona di eru.

Olotu: Igbẹhin ọdalẹ ni awọn fi han ọ yẹn Alapara.

Alapara: Oluwa sọ wa ninu isa ọdalẹ.

Olotu: Adura ti o dun ni a ngba yẹn, ki awa paapọ sọ ara wa.

Alapara: Mo gba, mo gbọ, ododo ọrọ ni.

Olotu: Ni nwọn ba fi ere Oloye Awolowo se aisun ọdun moju?

Alapara: Bi enipe e wa nibẹ. Orin ti wọn kọ moju ọjọ na ni yi.:

Awolowo Baba Layinka Ma mikan
Iwọ lo ni Fọdira
Titi lọ
D'Ogbomọshọ
Iwọ lo ni
Awolowo baba Layinka Ọjẹ lo ni
Wọọsi
Alagbẹde UPP
Ko ti beba rọ
Rikisi pin
Iwọ l'oni Fẹdira
Awolọwọ baba Layinka Alasaid abowa
Ku ọla
Ologinni de tan
T'ekute ile
Yio paramọ
Awolowo de tan
T'egbẹ UPP
Yio jalu igbẹ
N'ipinlẹ Iwọ Orun.

Olotu: Alapara, ẹ ko wa rii pe ọrọ ti Jesu ti gbogbo wa nse ojo bi rẹ pelu Oloye Awolọwọ dọgba ?

Alapara: Bẹ ni o ri gan ani Judasi duro fun Akatanla.

Olotu: Bẹnani Jesu duro fun Awolọwọ.

Alapara: Judasi lo se iku pa Jesu, beeni Akatanla se jamba fun babasalẹ ẹgbẹ Afẹaitẹrr.

Olotu: Otitọ ni ọrọ rẹ. Ootitọ kii ku si ipo ika. Ija ki a maa d'ẹru awọn alatohunrinwa ni Awolọwọ nja fun k Akatanla ati awọn alatilẹhin rẹ to sọ pe ki o fo ki o niso, Sugbọn o ti daju pe "Kiki oju wa ni a o fi rii, ti a o si ma a wo ere awọn enia buburu! Alapara ka fi ire pade o.

Asọbade Ere Bọlu

(SATURDAY JANUARY 11, 1964.)

DIVISION I

Aston Villa	v Blackpool	1
Bolton	v Arsenal	2 (x)
Burnley	v Everton	1
Fulham	v West Brom	2
Ipswich	v Sheffield W.	x
Leicester	v Stoke	x
Liverpool	v Chelsea	1
Man. U.	v Birmingham	1
Sheffield U.	v West Ham	x
Tottenham	v Blackburn	2
Wolves	v Nott F.	x (2)

DIVISION II

Charlton	v Newcastle	1
Derby	v Nor'ton	x (2)
Grimsby	v M'brough	2
Leeds	v Man. C.	1
Leyton	v Swansea	x
Plymouth	v Hud'sfield	2
Portsmouth	v Cardiff	1
Preston	v Sou'pton	1
Rotherham	v Swindon	1
Scunthorpe	v Norwich	2
Sunderland	v Bury	1

DIVISION III

Bournemouth	v Col'ster	1 (x)
Bristol R.	v P'borough	x
Crewe	v Sh'sbury	2
Crystal P.	v Brentford	1
Hull	v Millwall	1
Luton	v Barnsley	x (2)
Notts C.	v Bristol C.	2
Port Vale	v Oldham	x
QPR	v Sout'end	x (1)
Reading	v Coventry	2
Walsall	v Mansfield	1
Wrexham	v Watford	2

DIVISION IV

Bradford	v Doncaster	x
Che'field	v Southport	2
Darlington	v Bradford C	x
Exeter	v Gillingham	2
Halifax	v Carlisle	x (2)
Har'pools	v Lincoln	2
Newport	v Chester	1
Oxford	v Barrow	1
Rochdale	v Torquay	x
Stockport	v Brighton	2

OWE ILẸ YORUBA

1 Owe lẹsin ọrọ bi ọrọ ba sọ nu owe ni a fi nwa.
2 Bi ọko lọ okun, bi o lọ ọsa o tun nbọ wa fi ori fun elebute
3 Ọmọ ti yio jẹ asamu lati kekere ni o ti ma jẹ ẹnu samu samu
4 Ẹni to jin si koto o kọ a.a yo ku lọgbon
5 Ọkan ẹni ni Alufa ẹni
6 Iwa tirẹlẹ lẹsọ enia
7 Aiyegba tapa o kole Igunnu.
8 Ba mi na ọmọ mi ko de inu ọlọmọ
9 Ọro ko dun gboro, bi a fẹ laro a ru lale.
10 Kosi lowo tass to je amala rẹ ko siwo, eni fi egusi se ifimo lo jẹbi.
11 Diẹ lọwọ ọkọ, diẹ lọwọ aya
12 Abanije ni ko igba iyi
13 Eni da eru le ru nto
14 Elulu to fa ojo, ori ara rẹ ni yio fi ru
15 Bi arigisegi basegi ori ara re ni yio fi ru
16 Ẹrukọ npa ara rẹ, o ni on pa ọkọ
17 Kaka ki o san lara iya aje ofi gbogbo ọmọ rẹ bi obirin
18 Teni begi loju, igi atun ru we
19 Olowo je, otosi je tile tile olowo ni Otosi ko fi tun arare se
20 Abi ikọ, a kọ ọ gba, ati ita ni wọn ti kẹ wọn wa sile.

ALỌ O

1 Agbagba meji sun tira won ako mo egbọn ako mo Aburo
2 Ikoko dudu fehin ti gbo
3 Ọpatinrin kan lẹ o kan run
4 Kini ba ọba jẹun ti ko pale mo
5 Kini koja ni ta oba ti ko ki oba
6 Kini gba oba leti ti ko ki
7 Oko baba mi kan ti aba wa isu nina re ti aba se, ako le je tan
8 Kini bo sinu omi ti ko ku
9 A ran omo lakara akara siwaju omo dele
10 Oruku tindi oruku tindi tindi oruku bi gba omo ole tiro fun gbogbo won.

Itumọ Alọ

10 Ewa
9 Ekin Ope
8 Oyin
7 Ọmu
6 Yanmuyanmu
5 Agbara Ojo
4 Esinsin
3 Ojo
2 Igbin
1 Oju

Irohin Yoruba

Fęlęmulagbe ba ęmu ku

Okunrin ti nda ęmu kan Ukpe Udoma ja bọ lori ọpẹ ọmọ kan ti o gun ni adugbo [illegible] ni ọjọ ọdun titun ku ọla ni Ugongwono ni agbegbe Aba, o si ku gbe.

Ukpe ti gun ọpẹ na, o si ti da ęmu rẹ lati fi ghadun ọdun titun, sugbọn gẹrẹ ti [illegible] lati ori ọpẹ, ti o si ja bọ, pe ni agbe ęmu rẹ fọ [illegible] ti ęmu inu rẹ si [illegible] o ja bọ si. Oju kanna ni o si ku si.

Okunrin akọpẹ kan ẹni ọdun marundinlogoji Nwachukan Okpara bọ lori ọpẹ ni abule Mbole ki eba Aba ni ojo ọdun ku ọla, o si ku gbe.

* IROHIN kan ti o tẹyọ si eti igbọ wa ni aipẹ yi fi han pe ọwọ awọn ọlọpa ti tẹ obunrin kan ti o fẹ mọmọ pa ara rẹ ni ile Ikire ni Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria laipe yi. Obinrin na si wa ni abẹ itọju awọn ọlọpa bayi.

* Irohin kan lati Ijebu fi han wa bakanna pe awọn ọlọpa Ijebuode ti mu ọkunrin kan, ara Adugbo Lekuti ni Ijebu ti o gbe ibọn ti awọn ki ẹin arin igboro lai ni iwe.

Irohin na ti o jade lati ẹka ile iṣẹ awọn ọlọpa ni Ibadan fihan pe awọn mu okunrin na ni iha ile Igbadun "Paramount Hotel" Ijebu-Ode ni ọjọ ọdun Keresimesi ku ọla.

'EBOH, OSAGIE KẸRAN

AWỌN ọmọ ẹgbẹ Afẹnifẹre ni agbegbe Kano ti bu ẹnu ẹtẹ lu iwa gbọn-omi-si-omi-o to ti Oloye Festus Okotie-Eboh ati Oloye Ọmọ-Osagie nfi ṣe iṣelu Ipinlẹ Agbedemeji Iwọ Orun Naijiria (Mid-West). Bakanna ni nwọn si bu ẹnu ẹtẹ lu iwa awọn oṣelu meji yi ni siso ara wọn di ohun elo ẹgbẹ Olomi (NPC) lati ri aye pọ wọ inu iṣelu iha Guusu Naijiria.

Awọn ọmọ ẹgbẹ na ṣe alaye ninu iwe ti nwọn fi sọwọ si ile irohin wa pe, "ọgbọn ẹru ti awọn Oloye meji yi nda ti awọn fi tako idapọ ẹgbẹ Afẹnifẹre ati Alakukọ ni Ipinlẹ Agbedemeji Iwọ Orun ni lati ri ọna da rogbodiyan silẹ larin awọn aṣaju Olufẹ otitọ ati idẹra larin ẹgbẹ mejeji, ki nwọn le ri aye mu alẹ gbọ Sardauna lori ipinnu pe on ni yio jẹ gaba lori gbogbo ilẹ Naijiria.

Awọn ọmọ ẹgbẹ na si pe awọn Oloye meji yi ni ija pe ki nwọn so l'aiye gbo ti awọn kii ba ṣe paramolẹ alagbaṣe ẹgbẹ Olomi ninu ẹgbẹ Alakuko.

Awọn ọmọ ẹgbẹ na si fi siwaju pe akoko na tito ti o yẹ ki awọn ọkunrin meji yi so ipo wọn ninu iṣelu Naijiria.

Awọn ọmọ ẹgbẹ na sọ lori ẹsun iwa buburu ti awọn Oloye meji na fi kan ẹgbẹ Afẹnifẹre pe awọn Oloye meji yi ni o buru fun ara wọn ki iṣe ẹgbẹ kan.

Nwọn si ṣe alaye siwaju pe, gbogbo enia ni o mọ bi iwa ẹgbẹ Olomi ti buru to ni orilẹede yi, o buru tobẹ ti nwọn ko fi ni ifẹ si alafia ati itura ẹnikọkan ni aye ara rẹ sugbọn igbagbọ wọn duro lori itẹsiloriba ifi ọmonikeji won sẹru, kiko arakunrin won ju si igbekun, ati gbigbe awon omo ẹgbẹ iṣelu ti o tako wọn lori ododo sẹwọn.

Yoruba kọ Ẹgbẹ Ọlọfin

(Bẹrẹ lati oju ewe kini) so ni Ibadan ni ojo kẹta osu kini odun yi, o ṣe alaye pe, "Ẹgbẹ Afẹnifẹre ko tako idasile ẹgbẹ Ibile gidi fun awon omo Yoruba.

"Ṣugbọn ẹgbẹ Afẹnifẹre ko nani ẹgbẹ omo Ọlọfin nitori awon idi won yi:

* Awon Asoju ẹgbẹ Omo Oduduwa ti o wa si ipade na titi eau Dokita Akanni Doherty ati Oloye Akinfenwa so fun awon Oba, ijoye, alakoso ijoba ati awon adajo pe awon ko lagbara lati fi owo si ipinnu kokan lai ti gba imoran Igbimo ẹgbẹ won.

"Lori gbogbo eyi nwon ni nwon pari 'gbogbo rogbodiyan,' ti nwon si da ẹgbẹ titun sile. Gbogbo eleyi si ṣẹlẹ lojukoju awon adajo ile ẹjọ giga wa".

Egbẹ Oduduwa

Lati oju ewe kini

awọn omo Yoruba.

Ninu ọrọ rẹ, Ọdẹmọ ti Ishara, Ọba Alaiyejuwa Samuel Akinsanya ṣe pe on woye pe, eto lati da ẹgbẹ oṣelu titun silẹ lo fa ipade si Ẹgbẹ Ọmọ Yoruba na pe.

Ara awo Oba ti o tun sọrọ lẹle Oba Akinsanya ni Awujalẹ Ijẹbu, Oba Sikiru Adetona. O so pe ohun ti on ro ipade ẹgbẹ na si nipe Dokita Majẹkodunmi fẹ da ẹgbẹ oṣelu titun silẹ.

O tako ete Dokita Majẹkodunmi pe bi o ba jẹ nitoto ni Dokita Majẹkodunmi nfẹ isọkan awon omo Yoruba, o yẹ ki o ti ṣe bẹ ni odun 1962 nigbati o fi jẹ Alakoso Ijoba Pajawiri ni Ipinnlẹ Iwo Orun.

O wa bere "kini Dokita Majẹkodunmi wa fẹ ki a ṣe nisisiyi nigbati o ti padanu anfani rẹ ni ọdun 1962 lati wa isokan awon ọmọ Yoruba?"

Nigbati ariyanjiyan gbona gidi lori ọrọ yi ni awon oba fi ori ba ori ti nwon si kede fun ipade na pe ki ẹgbẹ Omo Yoruba n.a jẹ Egbẹ Omo Olofin, ki awon Oba si ma jẹ Ẹgbẹ Omo Oduduwa nitori 'awa ko le gba ki oruko Oduduwa parẹ."

Ipade ala kan yio wa ni Ile Ifẹ ni ọjọ kokandinlogun osu ti o mbọ fun idasilẹ ẹgbẹ Omo Olofin eyiti Ẹgbẹ Omo Oduduwa ko lowo si.

MALAMA INA NUSA
Ogbonkangi ọmọ Ẹgbẹ Afẹnifẹre ni Oke Oya

AWỌN OBINRIN BU ẸNU ẸTẸ LU BELLO

APAPO ẹgbẹ Afẹnifẹre Obinrin Naijiria ti fi ilodi si wọn han si iṣapọ alafia Olola Ipinlẹ Ariwa Najiria, Alhaji Ahmadu Bello, lori eto awọn Obinrin Ipinlẹ na lati dibo tabi ki a dibo fun wọn.

Nibi ipade na, ẹgbẹ Afẹnifẹre Obinrin se atako ọrọ-afikita ti Sardauna sọ pe [illegible] awọn Obinrin ni anfani lati dibo. Awọn sọ pe Olola Ahmadu Bello tiiji lati sọ idi pataki eyiti o ni lakaye kosi fun awọn gbọ [illegible] ọrọ na.

Nigbati Olola Ahmadu Bello dari nina irin ajo rẹ si India, Pakistani ati orilẹede Arab de ni o sọ [illegible] fun awọn oniroyin [illegible] ni Kaduna pe Ijọba on le fun awọn Obinrin Ipinlẹ Ariwa ni anfani idibo nigbati asiko ba to.

Olola Ahmadu Bello wa se afikun ọrọ rẹ pe awọn yio fun awọn Obinrin Ipinlẹ Ariwa Najiria lanfani a ti dibo nigbakugba ti asiko ba to lati yan Arẹ-eleyi ni alakoso fun orilẹ-ede Naijiria.

IBANUJẸ

Ẹgbẹ Afẹnifẹre Obinrin na sọ pe itumọjẹ nlanla ni ọrọ ti o jade lẹnu Olola Ahmadu Bello na jẹ, o si le jẹ okuta idigbolu fun isọkan orilẹ ede, pọpọ ti [illegible] ọrọ yi ba njade lati enu [illegible] enia ti o wa ni ipo ti Sardauna wa lowi ni Naijiria.

Ẹgbẹ na si ikede Sardauna na fi [illegible] ẹgbẹ iselu fi ẹgbẹ Olomi [illegible] kan gbogbo enia gege bi ẹgbẹ [illegible].

Ẹgbẹ na wa [illegible] anfani lori ipo ti awọn Obinrin Ipinlẹ Ariwa Naijiria yio wa laipẹ iwaju, nwọn wa pinnu lati kesi gbogbo awọn enia ti o ba nife si ilọsiwaju orilẹ-ede Naijiria lati di ara wọn pọmọ ki nwọn si gbogun ti iru iwa [illegible] awọn aṣiwaju Ipinlẹ Ariwa.

Janduku Alakukọ gbẹwa

LẸNULOLO si Adajọ kotu giga Ikeja ju awọn janduku Alakukọ merin si ẹwọn osu mejilelogota.

Awọn janduku merin na ni Ezea Chrstopher, Salvester Onyekwere, Onyekwusi Mebolisa ati Johnson Nwosu.

Adajọ na ni ki awọn janduku merin yi lọ fi ẹdẹgberin o le ọgbọn ponun jura, ki nwọn si na ẹnikọkan wọn ni ẹgba merinlelogun tabi ki nwọn fi oṣu mejilelogota gbara lẹwọn.

Awọn ọkunrin merin na jẹbi ẹsun meji ti nwọn fi kan wọn lori iwa idaluru, tita jamba fun Ogbẹni Fatai Okulaja ti iṣe oṣiṣẹ kan ni ibi iṣẹ ọkọ ofurufu ni Ikeja larin osu kẹrin ọdun ti o kọja.

Ẹsun ti nwọn fi kan wọn nipe, awọn ọdaran na wa si ibi isiko ni ọjọ iṣẹlẹ yi lati dagbeirẹ fun alakoso ọmọ ẹgbẹ won kan laigba we iwole si ibi isiko na.

Ogbẹni Tony Daboh alabo ni ibi isiko na ti o jẹri gbe Ogbẹni Okulaja sọ ninu ọrọ rẹ pe awọn ọdaran na fi agbara ti Ogbẹni Okulaja nigbati ko gba wọn laye lati wọle.

O fi kun un pe hirikiti ni awọn ọkunrin na yii ka ti nwọn si berẹ si na Ogbẹni Okulaja ti nwọn si na iẹyun ki nwọn to fẹsẹ fẹ ẹ.

Ninu idajọ, Adajọ Ogbẹni T. A. Makanju; o ni ki ọdaran kini iyini Christopher lọ san ọgorun ponun, ki o si je ẹgba mẹfa tabi ki o fi osu mẹfa sẹwọn.

O si ni ki ẹnikọkan ninu awọn ọdaran mẹta yoku lọ san igba ọ le mẹwa ponun ki nwon si jẹ ẹgba mẹjọmẹjọ tabi ki nwọn fi oṣu mẹjọmẹjọ sẹwọn.

Ibadan binu si ijoba Akintola

ỌBA, Ijoye ati awọn ọmọ ilu Ibadan ti fi ibinu wọn si ijọba Akintola han ninu iwe kan ti nwọn kọ si Oloye S. L. Akintọla Olotu ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun lori pipa awọn ile ẹjọ ibilẹ rẹ ni ilu na.

Ninu iwe kan ti awọn ijoye mejila fi ọwọ si, ti nwọn fi ṣe ranṣẹ si Olotu na, nwọn se alaye pe iwa aleba ati ikorira gba ni pipa awọn kotu ibilẹ na rẹ lati fi ṣe awọn ara Ibadan di ẹnia ti ko ni iru ni idi.

Nwọn si ṣe Ikekasi pe, "bi o ba jẹ atunse ti o tọna ninu awọn kotu ibilẹ yi ni Ijọba nse gegebi nwọn ti ṣe ikede, atunse na yẹ ki o jẹ eyiti yio kari gbogbo kotu ibilẹ ni Ipinlẹ Iwọ Orun. Sugbọn ni iwọn igbati ko fi kari, ẹrọ wa ni lati fi siwaju pe ona lati ko inira ogun ala ba awọn ara Ibadan ni o jẹ lati se 'gbiyanju' atunṣe yi ni ilu Ibadan nikan.

NTC

EYI NIFILỌ PATAKI FUN AWON TO NSISE OWO TABA NILẸ NAIJIRIA

Ki a to [illegible] ti yio ba akoko yi ma nipa [illegible] iwole owo nile Naijiria, ajọ awọn to nbojuto [illegible] awọn to nse Siga, tie N.T.C. nse ifilo wipe awon o tikan owo taba ti a gbin nile Naijiria.

Ninu eto ti alaga ajọ na so, O ni awọn o na Oke Medogbon ponun lati fi ra owo taba ti wọn o gbin ninu Odun ta o bọnà yi. Eyi ma jẹ ki a fi ọkẹ meji ale ẹdẹgbajo ponun kun owo to nbọ si ọwọ awọn agbẹ. O dun wa wipe ọgbin yi ko dagba to bo ti yẹ lodun yi nitori ọjọ ati orun ti ko se tarara ni dede eyiti o ba ọgbin na mu, iba sta sibe ni, ilopo meji eyiti won mu jade yen ni iba jade. owo rẹ iba si to adota ọkẹ ponun ti yio bọ sọwọ awon agbẹ.

Iye owo oja titun nisiyi fun taba t'oke Oya ati ti Guusu ti a sagbe ninu afẹfẹ la o ma ta bayi:-

Grade	1 Sile meji kọbọ merin iwọn kan.		
"	2 Sile meji odun kọbọ	"	"
"	3 Sile kan kọbọ mejo	"	"
"	4 Sile kan atọre	"	"
"	5 Kọbọ mejọ pere	"	"
"	6 Toro toro iwọn.		

Ni Odun 1933 eyiti se ọgbọn odun sẹhin la koko gbin taba ti afi nse siga ti ama afi ọrọ si nile Nigeria yi. [illegible]

Ki ise awọn agbẹ ba le tẹsiwaju dada, awọn to nse siga nile Nigeria ti atẹ ni N.T.C. won gba owo pupọ [illegible] ki won mọ nipa taba dada, ti won o ma lo kakiri gbogbo iban ti ngbin taba, ti won si nla oye se awon agbẹ nipa orisirisi eto ti a fi ntoju taba ati nipa ilo ogun ledu ati bi a ti npa awon kokoro to nje ogbin.

AWON TO NṢE SIGA TO DARA JU NI NAIJIRIA.

Published by the Eastern Post Limited, Elephant House 214 Broad Street Lagos and printed for them by the African Press Ltd, O. Box 78, Ibadan, Editor: E. O. OLOFIN, c/o 98, Shita Street, Ibadan.